Njinga & Sepé: Revista Internacional de Culturas, Línguas Africanas e Brasileiras
São Francisco do Conde (BA) | vol. 5, nº Especial I | p. 80-110 | jan./ jun.2025.

# Ìtúpalẹ̀ Ìṣàfihàn Èrò Ìjìnlẹ̀ nípa Agbára Olódùmarè, Ìsọ̀rí Ìṣẹ̀dá Abẹ̀mí, àti Ajẹmẹ́ranko nínú Ìlò Oríkì

# A Socio-Cultural Analysis of Power of Creator, Creatures, and Animatory Creatures through the use of Oríkì

**Adéọlá Adijat FÁLẸ́YE** *
ORCID iD https://orcid.org/0000-0001-7059-3153

**ÀṢAMỌ̀**
Onírúúrú àkíyèsí ni ó ti wà ṣaájú iṣẹ́ ìwádìí yìí tí ó fi hàn pé, ìran Yorùbá jẹ́ ìran kan tí wọ́n kún fún àkíyèsí, àti àròjinlẹ̀ nípa àyíká wọn. Bákan náà ni pé, ìran Yorùbá kún fún àròjinlẹ̀ nípa ìgbésí ayé tí wọn ń gbé. Àìdéyẹ sí ìgbàgbọ́ nínú èrò ìjìnlẹ̀ wọn pé Olódùmarè ni orí fún gbogbo ìṣẹ̀dá, yálà abẹ̀mí, tàbí aláìlẹ́mìí jẹ́ ohun tí wọ́n máa ń fi hàn níbikíbi ti wọn bá ti ní ànfààní. Ní pàtàkì, wọ́n ń ṣe àfihàn àwọn nǹkan ìṣẹ̀dá ọwọ́ Olódùmarè nínú ìlò oríkì tí wọ́n máa ń ṣẹ̀dá. Èyí hàn gbangba nínú oríkì tí wọ́n ń hun fún àwọn ohun ìsọ̀rí abẹ̀mí ajẹmẹ́ranko tí wọ́n gbà pé Olódùmarè dá, tí ènìyàn ń sìn, èyí tí wọn kì í sìn, àti àwọn ẹ̀dá inú omi. Nítorí náà, nínú iṣẹ́ ìwádìí yìí, a tọ́ka sí aagbọn ìṣàmúlò oríkì gẹ́gẹ́ bí abala kan pàtàkì tí Yorùbá fi ń fi àròjinlẹ̀ wọn hàn nípa nǹkan àyíká wọn, tí ó jẹ mọ́ ìṣe, ìhùwàsí àti àkíyèsí wọn, nípa àwọn ìsọ̀rí ìṣẹ̀dá abẹ̀mí àti àwọn ìṣẹ̀dá ajẹmẹ́ranko àyíká wọn. Ìlànà ìwádìí tí a lò ni ṣíṣe àkójọ àwọn àròfọ̀, oríkì àti orin àwọn apohùn fún àwota. A ṣe àgbéyẹ̀wò àkóónú ìpèdè oríkì tí ó gbajú-gbajà tí àwọn apohùn hun jọ, fún àfihàn àwọn ìjẹlógún èrò iṣẹ́ yìí. A ṣe àgbéyẹ̀wò ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn oríkì tí ó wà lórí àwọn ìsọ̀rí ìṣẹ̀dá abẹ̀mí tí a ṣà yàn fún àlàyé kíkún. Tíọ́rì Ìfojú-Àṣà-Ìbílẹ̀-wo iṣẹ́-ọnà lítíréṣọ̀ ni a fi ṣe àwòta fún ìtúpalẹ̀ láti fi hàn pé, èrò àròjinlẹ̀ nípa ìṣesí, ìhùwàsí àti ìrísí àwọn ìṣẹ̀dá abẹ̀mí tí a tọ́ka sí nínu iṣẹ́ yìí, ni ó bí ìlànà ìhun oríkì tí ìran Yorùbá ṣe àgbékalẹ̀ rẹ̀. Iṣẹ́ yìí túnbọ̀ fi òye kíkún hàn nípa bí ìgbàgbọ́ ìran Yorùbá ṣe lóòrìn tó, nípa ìpèdè “Aṣẹ̀dá, Olúdá ayé àti ọ̀run, àti “Olùdá ohun gbogbo” tí àwọn onímọ̀ kan ti fún Olódùmarè. ẹ̀wẹ̀, a se àfihàn bí ìran Yorùbá ṣe ní ìgbàgbọ́ púpọ̀ nínú agbára Olódùmarè, Ìyà mi, àjọṣepọ̀, àti ojúṣe àwọn nǹkan abẹ̀mí sí ara won nínú ìpèdè oríkì tí a se ìtúpalẹ̀ nínú iṣẹ́ àpilẹ̀kọ yìí láti fi ìdí èrò múlẹ̀ pé, ìsesí, ìhùwàsí àti àwọn àbùdá ẹ̀dá kọ̀ọ̀kan ni ó ń ran alátinúdá lọ́wọ́ fún ìhun oríkì tí wọ́n ń hun.

**KÓKÓ ỌRỌ̀**
Ìran Yorùbá, Èrò Ìjìnlẹ̀, Agbára Olódùmarè, Ìṣẹ̀dá Abẹ̀mí, àti Ìlò Oríkì

**RESUMO**
Houve várias observações antes desta pesquisa que mostram que o povo iorubá é um povo repleto de observações e imaginação sobre seu ambiente. Da mesma forma, o povo iorubá é repleto de imaginação sobre a vida que leva. A crença profunda de que Deus é a cabeça de toda a criação, seja animada ou inanimada, é algo que demonstram sempre que têm oportunidade. Em particular, demonstram as criações de Deus por meio da poesia que criam. Isso é evidente na poesia que compõem para as criaturas que acreditam ter sido criadas por Deus, aquelas que adoram, aquelas que não adoram e as criaturas aquáticas. Portanto, nesta pesquisa, nos referimos ao uso da poesia como um

---

* Fellow of the American Council of Learned Scholars, Lecturer @ Department of Linguistics and African Languages, Faculty of Arts, Obafemi Awolowo University, Ilé-Ifẹ̀, Òsun, Nigeria E-mail: adeolaye@oauife.edu.ng

aspecto importante da maneira iorubá de expressar seus pensamentos sobre seu ambiente, ou seja, suas ações, comportamentos e observações sobre as criaturas da natureza e as criaturas de seu ambiente. O método de pesquisa utilizado foi coletar poemas, canções e cânticos dos poetas para o propósito do estudo. O conteúdo dos poemas mais populares escritos pelos poetas foi analisado para demonstrar os dez princípios deste estudo. Diversos poemas sobre o tema da criação da alma foram analisados e selecionados para uma análise detalhada. A teoria da perspectiva nativa americana sobre obras literárias é utilizada como estrutura para o estudo, a fim de demonstrar que a profunda compreensão das ações, comportamentos e aparência das criaturas mencionadas nesta obra deu origem aos princípios poéticos sobre os quais o povo iorubá se baseou. Este trabalho também demonstra uma compreensão completa do quanto o povo iorubá acredita na poesia, por meio da linguagem de "Aṣẹ̀da", "Oludu aya at ọ̀rún" e "Oludu ohun gbogbo", que alguns estudiosos atribuíram a Olódùmarè. Neste trabalho, demonstramos o quanto o povo iorubá acredita no poder de Olódùmarè, Iyà mi, àjọepọ e nas responsabilidades dos seres vivos uns para com os outros, na linguagem poética apresentada neste artigo, para estabelecer a ideia de que as ações, os comportamentos e as características de cada criatura são o que os poetas usam para tecer a poesia que tecem.

**PALAVRAS-CHAVE**
Povo iorubá, Pensamento: O Mistério, o Poder do Todo-Poderoso, a Criação da Alma e o Uso da Poesia

## 1.0 Ìfáárà

Yorùbá jẹ́ èdè pàtàkì, tí ó gbajúgbajà, tí àwọn ìran Yorùbá ń sọ lẹ́nu. Bákan náà ni ìsọ̀rí àwọn ẹ̀dá ènìyàn tí wọ́n wà ní abẹ́ àká ìran yìí kún fún àròjinlẹ̀ púpọ̀ nípa ìgbésí ayé tí wọn ń gbé. Ní pàtàkì, àròjinlẹ̀ àwọn ẹ̀dá ènìyàn yìí máa ń jẹ́, lórí ìṣẹ̀lẹ̀ àyíká wọn, ìṣe, ìhùwàsí, àti àkíyèsí àwọn nǹkan àyíká wọn, ní èyí tí ó máa ń fi agbára Olódùmarè lórí àwọn nǹkan ìṣẹ̀dá náà hàn. Bí ìran Yorùbá ṣe ní ìgbàgbọ́ púpọ̀ nínú agbára Olódùmarè, bẹ́ẹ̀ náà ni wọ́n tún gbà pé ìbáṣepọ̀ tí ó lóòrìn wà láàrin ènìyàn àti àwọn ohun ìṣẹ̀dá mìíràn tí Olódùmarè dá sínú ayé. Gẹ́gẹ́ bí ìkínlẹ́yìn èrò Àjàyí àti Ajíbádé (2021), ẹ̀ri wà pé ìbáṣepọ̀ wà láàrin ènìyàn àti àwọn ẹranko ilé tí àwọn ènìyàn ń sìn. Nítórí náà, a lè sọ pé ọ̀rọ̀ ìbágbépọ̀ láàrin ènìyàn, àti àwọn ohun ìṣẹ̀dá mìíràn láwùjọ Yorùbá máa ń ṣe okùnfà àhunpọ̀ oríkì fún àwọn ìṣẹ̀dá mìíràn, tí kì í ṣe ènìyàn.

Nítorí náà, ọ̀kan-ò-jọ̀kan èrò àròjinlẹ̀ àwọn ìran Yorùbá nípa àwọn ẹ̀dá mìíràn tí ó ń bá wọn gbé àyíká wọn, ìṣe, ìhùwàsí àti àkíyèsí àwọn nǹkan àyíká abẹ̀mí ajẹméranko bẹ́ẹ̀ ni a ó máa yẹ wò nínú iṣẹ́ yìí. Ní pàtàkì, láti fi ìlò oríkì láwùjọ ìran Yorùbá, àti agbára ìṣẹ̀dá àlátinúdá àwọn apohùn hàn. Bákan náà, bí àwọn ìṣẹ̀dá abẹ̀mí wọ̀nyìí ṣe ń fi agbára Olódùmarè hàn lórí àwọn nǹkan ìṣẹ̀dá mìíràn nínú ìlò òrìkì jẹ́ àfojúsùn, àti ìjẹlógún èrò fún àgbéyẹ̀wò iṣẹ́ ìwádìí yìí. Fún ìdí àfojúsùn wa, a ṣe atótónu iṣẹ́ lámèétọ́ lórí aáyan àwọn ọ̀mọ̀ràn ìṣaájú, àti ìlànà tí Yorùbá fi ń ṣe àmúlò èròja pàtàkì, tí ìran Yorùbá ń pè ní oríkì, ọ̀kan nínú ẹ̀yà lítíréṣọ̀ alohùn Yòrùbá.

## 2.0 Ìlànà Àmúṣe Ìṣẹ́, Ààlà Ìwádìí àti Tíọ́rì Àmúlò

Ìlànà àmúṣe iṣẹ́ yìí pín sí ọ̀nà mẹ́rin pàtàkì. Lákọ̀ọ́kọ́, a wo ìsọ̀rí ìṣẹ̀mí tàbí ìṣẹ̀dá abẹ̀mí tí Olódùmarè dá. A pín wọn sí ìsọ̀rí mẹ́rin pẹ̀lú àlàyé. Láti lè ṣe àkóyawọ́ àlàyé lórí àfihàn bí ìran Yorùbá ṣe ń ṣe àmúlò oríkì fún àfihàn agbára Olódùmarè, nípa ìṣẹ̀lẹ̀ àyíká, àti àwọn ohun ìyanu mìíràn láyìíka wọn, a ṣe àmúlò àkójọ oríkì àwọn ìṣẹ̀dá ènìyàn (ajemáko-mábo), ìṣẹ̀dàá abẹ̀mí tí wọ́n jẹ́ alágbára (ajẹmákọ-mábo, ní pàtàkì “Ìyà mi”), àwọn ìṣẹ̀dá abẹ̀mí ajeméranko tí wọ́n ń bá ènìyan gbé (ajẹmákọ-mábo), àti àwọn ìṣẹ̀dá abẹ̀mí ajẹméranko tí àwọn ènìyàn ń sìn (ajẹmákọ-mábo), fún ìtúpalẹ̀. Bákan náà ni a ṣe

àfihàn àwọn ìlò-èdè àtọ́ka ìbáṣepọ̀ láàrin ẹ̀dá ènìyàn àti agbára tí Olódùmarè fún ọ̀kọ̀ọ̀kan àwọn ìṣẹ̀dáá abẹ̀mí ajẹmẹ́ranko tí iṣẹ́ ìwádìí yìí ń ṣe ìtúpalẹ̀ wọn hàn.

## 2.1 Àalà Iṣẹ́ yìí àti Iṣẹ́ Ìṣaájú

Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé iṣẹ́ ti wà tẹ́lẹ̀ lórí ìpínsísọ̀rí onírúúrú àwọn ẹranko (Ọláfimíhàn, 1953), pàápàá lórí àwọn ẹranko tí ó ń gbé inú igbó kìjikìji, àwọn kòkòrò tí ó ń gbé inú omi, èyi tí ó ń gbé inú ilẹ̀, àti àwọn mìíràn; a ní ìlànà tí a ṣàmúlò fún iṣẹ́ ìwádìí yìí, tí ó yàtọ̀ sí ìlànà ìpínsísọ̀rí àwọn aṣaájú ọ̀mọ̀ràn. Nítorí náà, a ṣe àtúnpínsísọ̀rí àwọn ìṣẹ̀dáá abẹ̀mí ajẹmẹ́ranko bí i àwọn ẹran ọ̀sìn, tí wọ́n ń bá ìṣẹ̀dá ènìyàn gbé inú ilé. Bákan náà ni a wo ìsọ̀rí ìṣẹ̀dá abẹ̀mí ajẹmẹ́ranko èyí tí ìṣẹ̀dá ènìyàn ń sìn, àti àwọn tí wọn kì í sìn, ṣùgbọ́n tí wọn ń bá ènìyàn gbé àyíká.

Ọláfimíhàn (1953:5) ti ṣe ìpínsísọ̀rí àwọn ẹranko lóríṣìíríṣìí gẹ́gẹ́ bí i àkíyèsí iṣẹ́ pàtàkì tí kò ṣe é fi ọwọ́ rọ́ dànù: àwọn ẹranko tí ó ń gbé inú ilé, àwọn ẹranko afàyàfà. Ó tẹ̀síwájú láti ṣe ìpínsísọ̀rí àwọn ẹranko tí ó ń gbé inú ilé, àti ọ̀nà tí gbogbo àwọn ẹranko fi jọ ara wọn. Kò ṣalái mẹ́nuba àwọn kòkòrò tí ó ń gbé inú omi, àti èyi tí ó ń gbé inú ilẹ̀. Àkíyèsì pàtàkì ni pé, iṣẹ́ ìwádìí yìí kọjá ààyè ibi tí ó jẹ́ iṣẹ́ dé, nípa pé, a ṣe àtúpín ìsọ̀rí ìṣẹ̀dá àwọn abẹ̀mí ajẹmẹ́ranko tí ó jẹ́ ìjẹlógún iṣẹ́ yìí. A ṣe iṣẹ́ ìṣẹ̀dá oríkì àwọn abẹ̀mí mîìran tí ó jẹ́ ọgbọ́n àtinúdá àwọn akéwì ni a ṣàmúlò. Bákan náà ni a ṣè ìtọ́kasí àwọn oríkì, iṣẹ́-ọnà orin tí àwọn apohùn lò nínú fọ́nrán ìgbàlódé fún àtúpalẹ̀ nínú iṣẹ́ yìí. Àmúlò ọgbọ́n àtinúdá ti òǹkọ̀wé yìí náà jẹ́ agbára fún oríkì tí a fi gbe èrò àtúpalè wa lẹ́sẹ̀.

Nítorí náà, iṣẹ́ àyẹ̀wò tí a ṣe fún ìwádìí yìí sún síwájú díẹ̀ ju ti Ọláfimíhàn (1953) àti iṣẹ́ Ajayí & Ajíbádé (2021) lọ. Gẹ́gẹ́ bí àtẹ̀gùn sí iṣẹ́ tí àwọn aṣaájú onímọ̀ ti ṣe, a ṣe àwárí àwọn oríkì tí ó fi ọ̀nà àrà nípa àròjinlẹ̀ èrò ẹ̀dá nípa Olódùmarè nínú àhunjọ oríkì fún àwọn ìṣẹ̀dá abẹ̀mí tí ó yàtọ̀ sí ti ènìyàn hàn. Àwọn oríkì tí a ṣe àkójọ wọn yàtọ̀ ní ìrísí. Bákan náà ni àwọn oríkì tí a ṣe àkójọ wọn ṣe àfihàn àtinúdá akéwì tí a lò, ní ìbámu pẹ̀lú àfojúsùn àkòrí inú bebà yìí. Ìpínsísọ̀rí iṣẹ́ ìwádìí tí a ṣe kò rìn bí i ti ìpínsísọ̀rí àwọn onímọ̀ ìṣaájú ṣe, bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé kò sí àríyànjiyàn lórí ohun tí wọ́n pe ìsọ̀rí àwọn ẹranko tí wọ́n pín sí ìsọ̀rí, síbẹ̀, fún ìdí àfojúsùn olùwádìí yìí, ààlà wà. Bákan náà, a ṣe àmúlò oríkì kọ̀ọ̀kan tí ó ti wà ní àkọsílẹ̀, ṣùgbọ́n ní àfíkún ọgbọ́n, gẹ́gẹ́ bí alátinúdá, olùṣèwádìí yìí ṣe àfikún oríkì àwọn ìṣẹ̀dá abẹ̀mí mìíràn tí kò sí ní àkọsílẹ̀ tẹ́lẹ̀, ní ìbámu pẹ̀lú èròngbà àfojúsùn iṣẹ́ yìí.

## 2.2 Tíọ́rì Àmúlò

Tíọ́rì ni ọ̀pákùtẹ̀lẹ̀ tí a fi ń ṣé òdiwọ̀n ìwádìí tí ó yè koorò. Ọ̀pẹ́fèyítìmí (2014) rí tíọ́rì gẹ́gẹ́ bí àyálò ọ̀rọ̀ tí ẹnu kò fi bẹ́ẹ̀ kò lórí àpèjúwe àti ìtumọ̀ rẹ̀. Ishola (2023) tọ́ka sí èrò pé ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn onímọ̀ ìṣáájú ni wọ́n ti ṣe àpèjúwe ohun tí tíọ́rì jẹ́ àti ìwúlò rẹ̀. Ọlátẹ́jú (2008) rí tíọ́rì gẹ́gẹ́ bí ọgbọ́n tàbí ète ìtọpinpin lítíréṣọ̀ tí àwọn onímọ̀ káàkiri gbé kalẹ̀ gẹ́gẹ́ bí ọ̀ná àmúṣe kan pàtàkì, tí ó sì jẹ́ ìrànwọ́ fún ìṣàtúpalẹ̀ tàbí ìtọpinpin iṣẹ́-ọnà kan. Òté èrò yìí ni a ṣàmúlò láti fi Tíọ́ri-Ìfojú-Àṣà-Ìbílẹ̀-wo iṣẹ́-ọnà lítíréṣọ̀ ṣe àwòta fún àtúpalẹ̀ ti a gùn lé nínú ìwádìí yìí.

### 2.2.1 Àlàyé nípa Tíọ́ri-Ìfojú-Àṣà-Ìbílẹ̀-wò Iṣẹ́-ọnà Lítíréṣò

Tíọ́rì àṣà ìbílẹ̀ jẹ́ èyí tí ìfilọ́lẹ̀ rẹ̀ wáyé láti ọwọ́ Douglas (1978). Douglas dá tíọ́rì àṣà sílẹ̀ gẹ́gẹ́ bí irin-iṣẹ́ tí ènìyàn lè ṣàmúlò fún iṣẹ́ ajẹmáwùjọ kan. Àlàyé rẹ̀ ni pé tíọ́rì àṣà máa ń ṣàlàyé bí àwọn ènìyàn ṣe lè ronú, àti bí wọ́n ṣe lè ṣe nínú ayé, àti ní àyíká wọn. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé àwọn agbátẹ̀rù tíọ́rì àṣà yìí pín sí igun méjì, àwọn tí ó gbé tíọ́rì àṣà rù, tí ó fi di ti káríayé jẹ́ ìsọ̀rí àkọ́kọ́. Lára wọn ni a ti rí Thompson, awyr (1990). Ohun tí wọ́n ń sọ ni pé, a lè lo tíọ́rì àṣà lọ́nà ìrọrùn, láti tanná wo èrò tí ó bá jẹ́ mọ́ ìgbàgbọ́ ìṣesí, ìhùwàsí àti àwọn nǹkan ìṣẹ̀ṣe tí Orílẹ̀-èdè kan ní, tàbí tí ẹgbẹ́ kan gbàgbọ́ nínú rẹ̀. Bákan náà ni wọ́n gbà pé a lè fi tíọ́rì yìí wo àwọn nǹkan àṣà, tí ẹ̀dá jogún bá láti ìgbà pípẹ́, àti bí ayé ṣe ń yí. Èrò Rotmans awyr (1994) tí ó jẹ́ ìsọ̀rí àwọn ọ̀wọ́ agbátẹ̀rù èrò kejì yapa díẹ̀ sí èrò Thompson. Ó gbà pé káríayé ni tíọ́rì Ìfojú-àṣà-ìbílẹ̀-wò iṣẹ́-ọnà jẹ́.

Kókó èro àwọn agbátẹ́rù tíọ́rì yìí ní ìtẹ̀síwájú èrò pé, tíọ́rì Ìfojú-àṣà-ìbílẹ̀-wò iṣẹ́-ọnà lítíréṣò jẹ́ àbá tí ó kúnwọ́ láti ṣàpèjúwe ojú àmúwayé àwọn ènìyàn àwùjọ nípa nǹkan tó wà nínú àwùjọ wọn. Nítorí náà, bí a bá wo kókó èrò àfojúsùn wa fún ìtúpalẹ́ ìlò oríkì tí àwọn apohùn, akéwì tàbí ọ̀kọrin ń ṣe àgbékalẹ̀ ìṣẹ̀dá rẹ̀ láwùjọ, a ó rí i pé ó kún fún èso ìgbàgbọ́ àwùjọ, àti ìrírí tí irú àwọn ìsọ̀rí ẹ̀dá bẹ́ẹ̀ ní, lórí nnkan àyíká wọn, ló ń fà a. A jẹ́ pé ète tíọ́rì yìí ni a fẹ́ ṣe àmúlò fún ìkápá ìtúpalẹ̀ wa. Bákan náà, àwọn agbátẹ́rù tíọ́rì yìí gbà pé àgbéjáde iṣẹ́-ọnà máa ń dáàbò bo àṣà, àti ìṣẹ̀ṣe àwùjọ kan. Èrò olùwádìí ni pé, ète ìdáàbò bo àṣà, ìgbàgbọ́ àti ìfipamọ́ èrò ni àwọn apohùn tí wọn ń ṣẹ̀dá oríkì fún àwọn ẹ̀dá abẹ̀mí, àti àwọn ajẹmẹ́ranko àwùjọ wọn ń ṣe. Nítorí náà, gẹ́gẹ́ bí i lámèyítọ́, ìjẹlógún àwọn agbátẹ́rù tíọ́rì yìí ni a ó mú lọ́kùn-ún-kúndùn láti fi ṣe àwotà fún ìtúpalẹ́ ìjẹyọ irú àwọn àṣà, ìgbàgbọ́ tí ó sú yọ nínú iṣẹ́-ọnà aláwòmọ́ lítíréṣọ̀ tí a ń pè ní Oríkì nínú iṣẹ́ yìí. Fún ìdí yìí, a wòye pé tíọ́rì Ìfojú-àṣà-ìbílẹ̀-wò iṣẹ́-ọnà tí a gùn lé nínú ìwádìí yìí, yóò wúlò púpọ̀. Pàápàá tí a ń wo ìsúyọ àwọn èso àṣà, ìṣe, ìhùwàsí ẹ̀dá, ìgbàgbọ́ nípa Olódùmarè gẹ́gẹ́ bí Olúdá ìṣẹ̀dá ènìyàn, àti àwọn ẹranko pẹ̀lú ìbágbépọ̀ wọn, pẹ̀lú ènìyàn abẹ̀mí yòókù láwùjọ.

## 3.0 Àgbéyẹ̀wò Aáyan ọ̀mọ̀ràn nípa Ìlò Oríkì

Gẹ́gẹ́ bí a ṣe mọ̀ pé ọ̀tọ̀ ni àáyè Orí ni gbogbo ẹ̀yà tí ó wà ní ara, a lè sọ pé láìsí orí, kò sí ohun tí a fẹ́ kì, tàbí ohun tí a fẹ́ kí lára ènìyàn. Bí kò bá sí orí, ẹ̀yà ara yòókù kò pé, ó ti di òkùsù nìyẹn. Abájọ tí èrò ìjìnlẹ̀ Yorùbá fi hàn nínú gbólóhùn yìí: "Orí ni ọba ara". Nítorí pé, Orí ni a fi ń dá ẹ̀dá ènìyàn àti ẹranko mọ̀ ní àwùjọ. Orí ni àdàpè ohun tí Yorùbá ń pè ní ẹlẹ́dá nígbà mìíràn. Ládélé (2008:174) pe Orí ni "olùdarí gbogbo ara", nítorí pé ibẹ̀ ni ojú tí a fi ń ríran, àti etí tí a fi ń gbọ́ran wà. Bákan náà ni ó jẹ́ pé inú apóló tí orí wà ni imú tí ẹ̀dá fi ń mí, tí a sì fi ń gbọ́ òórùn wà. ẹ̀wẹ̀, nínú àwùjẹ̀ ni ọpọlọ tí a fi ń ronú wà pẹ̀lú. Orí yìí náà ni ẹnu tí a fi ń sọ̀rọ̀ wà. Ní ṣókí, gbogbo àwọn ẹ̀ya ara yòókù tí Ẹlẹ́dàá (Aṣẹ̀dá) abẹ̀mí fi jíǹkí ẹ̀dá ni ó jẹ́ pé Orí ló gbé wọn ró. Nítorí ipò pàtàkì tí orí kó láwùjọ ọmọ ẹ̀dá ni Yorùbá fi máa ń ki oríkì. Nítorí nàá, lójú ìwòye wa, orúkọ àjùmọ̀jẹ́ tí ó jẹ́ ewì àtẹnudẹ́nu, tí a fi ń ki orí lọ́nà tí yóò fi dìde gàn-ìn, ni ìpèdè Oríkì jẹ́. Yorùbá máa ń ṣe àhunpọ̀ ohun gbogbo tí orí ṣe, ní ìlànà ohùn orin, ìsàré tàbí ní ìlànà ìsọ̀rọ̀kéwì, tí yóó sì dùn ún gbọ́ létí. Èyí gan ni a fi dá ìpèdè oríkì mọ̀ yàtọ̀ sí ọ̀rọ̀ ẹnu ṣákálá. Ní àtẹ̀gùn sí èrò Adébóyè (1969), a lè sọ pé èrò ìjìnlẹ̀, tí a ṣa èdè rẹ̀ yàn fún ìlò, tí a mọ̀-ọ́n-mọ̀ hun fún àgbéjade pẹ̀lú èdè àdídùn ni oríkì jẹ́.

Yorùbá máa ń lo oríkì ènìyàn láti fi ki ènìyàn, àti láti fi ṣàlàyé irúfẹ́ ẹ̀dá tí ènìyàn jẹ́. Tọkùnrin tobìnrin tí Adẹ́dàá bá fún ní ẹ̀bùn ohùn dídùn, ẹ̀bùn ohùn orin, tàbí ohùn tín-ín-rín, ni ó lè lo ohùn náà láti ki oríkì ènìyàn, tàbí ti ìṣẹ̀dá abẹ̀mí mìíràn. Irúfẹ́ àwọn ìṣẹ̀dá abẹ̀mí tí ó wà ní ipò tí a júwe yìí ni Yorùbá ń pè ní asunrárà, asùnjálá, apẹ̀sà-eégún, adégé, àti akùnyùngbà. Àmọ́ orúkọ àjùmọ̀jẹ́ fún ìsọ̀rí àwọn ẹ̀dá abẹ̀mí tí a dárúkọ sókè yẹn ni Yorùbá ń pè ní Apohùn.

Bóyá ni a rí òrìṣà ilẹ̀ Yorùbá kan tí kò ní oríkì. Àwọn olùsìn àwọn òrìṣà yìí kì í fi oríkì wọn ṣeré rárá. Ní pàtàkì, ní àsìkò ọdún wọn, nígbà tí wọ́n bá ń bọ àwọn òrìṣà yìí, onírúurú oríkì tí ó lè mú orí àwọn ènìyàn wú, tí ìpọ̀nrí àwọn òrìṣà yóò sì dìde tí àwọn apohùn bá n ṣàmúlò. Dáramọ́lá àti Jéjé (1995:67) fi yéni pé, oríkì jẹ ọ̀rọ̀ ìṣírí tí àwọn Yorùbá máa ń fi yin ara wọn, tàbí ẹni tí inú wọn bá dùn sí. Àṣà yìí ni a fi ń dá ènìyàn lára yá fún ohun rere tí ó ṣe tàbí láti fi hàn ènìyàn nígbà míìran pé inú wa dùn sí olúwarẹ̀. Bi ènìyàn bá ń ṣiṣẹ́ tàbí ó ń jó lójú agbo, bí ó bá gbọ́ oríkì rẹ̀, ara rẹ̀ á yá gágá, a sì múra sí ohun tí ó bá ń ṣe nígbà náà dáradára. Jéjé àti Dáramọ̀lá jẹ́ ká mọ̀ pé orísìírìṣìí ọ̀na ni a ń ki ènìyàn sí. Bí a tí ń ki ọba bẹ́ẹ̀ ni a ń ki mẹ̀kúnnù pẹ̀lú. Irú ọ̀rọ̀ tàbí aayò ọ̀rọ̀ ìjìnlẹ̀ bẹ́ẹ̀ tí ó súyọ nínú orúkọ ènìyàn tàbí iṣẹ́ rẹ̀ ni ìran Yorùbá ń pè ní oríkì.

Adéoyè (1982:41) sọ ọ́ di mímọ̀ pé Oríkì ọmọ ṣe pàtàkì láàrin Yorùbá; èyí ló sì fá ti Yorùbá fi máa ń fi àlejò tí ó bá ń jẹ́ orúkọ Yorùbá ṣe yẹ̀yẹ́ pé 'alórúkọ má lóríkì ọmọ.' Oríkì ọkùnrin a máa sáàbà fi ìwà akọni àti ti akínkanjú hàn, tí oríkì obìnrin a sì máa fi ìfẹ́, ìrètí àti ìyọ́nú wọn hàn. Ògúndèjì (1991:34) ṣàlàyé pé oríkì jẹ́ ewì alohùn tí Yorùbá máa ń

fi ṣe àpọ́nlé ènìyàn. Onímọ̀ náà rí oríkì gẹ́gẹ́ bí àkójọpọ̀ orúkọ àti ìpèdè àpọ́nlé tí Yorùbá fi ń ṣàpèjúwe ẹni (tàbí nǹkan) tí ó ní àwọn orúkọ àpọ́nlé náà, láti fi ìrísí, ìṣesí àti ìhùwàsí olúwa rẹ̀ hàn. Àjùmọ̀ní ni oríkì ìdílé, oríkì orílè, tàbí oríkì ìlú. Babalọlá (1975), àti Ògúndèjì (1991) pín oríkì sí oríkì orúkọ, oríkì àlàjẹ́/ìnagijẹ àti oríkì bọ̀rọ̀kìnní. Babalọlá (1975:4-5) gbà pé oríkì àlàjẹ́ lè gùn ju oríkì orúkọ lọ. Àpẹẹrẹ àlàjẹ́ tí ó fún wa ni, Eyínfúnjowó, Ọ̀pẹ́lẹ́ńgẹ́, Adúmáadán, àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Ògúndèjì (1991:35) sọ pé oríkì ìdílé, oríkì ìlú àti oríkì àjùmọ̀ni wà. Àpẹẹrẹ ohun tí ó ń sọ ni àwọn oríkì orílẹ̀ bí i ìran Oníkòyí, Arẹsà, Òpómúléró, Olúfẹ̀, Ìrèmògún, Olókùn-ẹsin, bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Ògúndèjì sọ ní pàtó pé, "ó fẹ́rẹ̀ má sí ohun tí Yorùbá kò ní oríkì fún. Bí àpẹẹrẹ wọ́n ní oríkì fún ikú, ewéko, oríṣìíríṣìí ẹranko, omi, òkè àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Kò sí àtàkò kankan bí ó ti wù kí ó rí, nípa èrò àwọn aṣaájú ọ̀mọ̀ràn pẹ̀lú ohun tí wọ́n sọ, àti aáyan wọn. Ohun tí a ṣe àwárí nínú ìwádìi yìí fi ìdí èrò àwọn ọ̀mọ̀ràn ìṣaájú náà múlẹ̀. ẹ̀rí tí a ní láti kín èrò wọn lẹ́yin ni èrèdí iṣẹ́ yìí, bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé iṣẹ́ ìwádìí yìí ṣe ìfẹ̀lójú lọ́nà mìíràn gẹ́gẹ́ bí àfikún iṣẹ́ tí àwon ọ̀mọ̀ràn náà ti ṣe.

## 4.0 Àsọyán nípa Àwọn Kókó ọ̀rọ̀ lójú Ìlò

### 4.1 Ìran Yorùbá

Onírúurú oríkì ni àwọn onímọ̀ ti fún ìran Yorùbá. E jẹ́ ká wo èrò ònímọ̀ kan Arèmú, et.all (2012: 283):

> *The Yorùbá people of the western coast of Africa are considered to be the largest single ethnic or tribal group among the many tribes that make up what eventually became known as Nigeria. While the majority of the Yorùbá live in western Nigeria, there are also a substantial number of people of Yorùbá descent who live in the Republic of Benin and Togo, in addition to large groups of Yoruba migrants living in the United States and the United Kingdom. The Yoruba nation is also said to be the most widely dispersed around the world through the trans-Atlantic slave trade. The descendants of the Yoruba nation in diaspora are commonly referred to as "Afro" cultures. They can be found in the US, Haiti, Cuba, Jamaica, Trinidad, Puerto-Rico, Dominican Republic, and Brazil.*

> Àwọn ìran Yorùbá tí wọ́n wà ní apá ìwọ̀-oòrùn ilẹ̀ Aáfíríkà ni a gbà pé ó jẹ́ ẹ̀yà tàbí ọ̀wọ́ ìṣẹ̀dàá kan pàtàkì tí ó tóbi jù lọ, tí wọ́n sì jẹ́ kí ọ̀pọ̀ ìlú mìíràn mọ̀ nípa Orílẹ̀-èdè Nàìjíríà. Nígbà tí ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn ènìyàn ìran Yorùbá n gbé ní apá ìwò-oòrùn Orílẹ̀-èdè Nàìjíríà, ọkẹ́ àìmoye àwọn ènìyàn ẹ̀yà Yorùbá tí wọ́n ń gbé ní Orílẹ̀-èdè àti Olú-ìlú Olómìnira Bìnì, àti Tógò, ní àfikún sí ògòòrò àwọn ìran Yorùbá mìíràn tí wọ́n pọ̀, tí wọn ti ya lọ sí Orílẹ̀-èdè Amẹ́ríkà àti Orílẹ̀-èdè United Kingdom. Ìran Yorùbá jẹ́ ẹ̀yà tí ó rin ìrìn-àjò, tí wọ́n sì fọ́n ká àgbáyé jù lọ nípasè ọ̀rọ̀ òwò-erú láti igun kan sí èkejì ayé. Àwọn ìran àrọ́mọdọ́mọ Yorùbá tí wọ́n wà káàkiri orílẹ̀ ayé mìíràn ni wọ́n sábà máa ń pè ní alásà "Afro". A lè rí àwọn wọ̀nyìí ní Orilè-èdè bí i US, Haiti, Cuba, Jamaica, Trinidad, Puerto-Rico, Dominican Republic, àti Brazil. (Aáyan ògbufọ̀ Olùṣèwádìí).

Pẹ̀lú àrífàyọ èrò onímọ̀ òkè yìí, àti ẹ̀rí ìwádìí mìíràn tí a ṣe, a lè sọ ọ́ yanya pé, ìran Yorùbá jẹ́ ìran tí ó kún fún onírúurú ọgbọ́n àgbékalẹ̀ nínú èrò ìjìnlẹ̀ wọn. Lítíréṣọ̀ wọn kún fún èrò ọgbọ́n, àti àwọn èròjà àmúyẹ fún ìgbáyégbádùn ọmọnìyàn (Fálẹ́yẹ, 2021). Àwọn ẹ̀yà Yorùbá lápapọ̀ fẹ́ràn òwò ṣíṣe. Bí a bá wo àwọn ẹ̀yà Yorùbá ọ̀yọ́, Ìgbómìnà, pàápàá àwọn

Ìjẹ̀ṣà, gẹ́gẹ́ bí ìjábọ̀ ìwádìí èrò (Fálẹ́yẹ, 2011) tí ó fi àwọn Ìjẹ̀ṣà ṣe àwòta fún ìran Yorùbá, tí ó sì fi hàn pé, wọ́n ní ìfẹ́ sí okòwò ṣíṣe púpọ̀. Yorùbá sì jẹ́ ìran tí ó kóni-mọ́ra. Ní kúkúrú, ìran Yorùbá jẹ́ ìran tí ó làjú, nípa ìrìn-àjò, wọ́n sì kún fún ìrírí, àti erò ìjìnlẹ̀ nínú àgbékalẹ̀ wọn.

## 4.2 Èrò Ìjìnlẹ̀

Yorùbá máa ń sọ pé, orí ni èròkerò ti ń wá. Ó já sí pé, ọpọlọ ni ẹ̀dá ènìyàn tàbí abẹ̀mí ajẹmẹ́ranko tí ó bá ti ní ẹ̀mí lára máa ń ṣàmúlò láti gbé ìṣe, ìhùwàsí àti ohun tí a bá pè ní èrò kalẹ̀. Ohun ti a rò kọjá ojú eréfèe ni ó ń jẹ́ èrò ìjìnlẹ̀. Nítorí náà, ìṣẹ̀lẹ̀ ni ó máa ń fa èrò. Nígbà ti ẹ̀dá bá ronú kọjá eréfèé, ti ó gbé ìrònú lọ sí abala ìhun ti ó jinnú, ti ó sì ṣe àmúlò àwọn ìpèdè àṣàyàn láti gbé èrò inú ọpọlọ náà jáde, ni a lè sọ pé ènìyàn ronú jinlẹ̀. Nítorí náà, ohun ti Yorùbá kà sí èrò ìjìnlẹ̀, àti bí a ṣe ṣàmúlò ìpèdè náà nínú iṣẹ́ ìwádìí ni akójọpọ̀ èrò ti ó kọjá ìwòye ìṣẹ̀lẹ̀ ní eréfèé, ṣùgbọ́n tí a fi àwọn àṣàyàn ọ̀rọ̀, oríkì, àkànlò-èdè, òwe, àhùnpọ̀ ìpèdè èdè ti ó ṣàfihàn ìlànà ìkánilára èrò ṣe àgbékalẹ̀ ìròrí àti ìrònú ẹni; ní ọ̀nà ti ó ní ìtumọ̀ fún olùgbọ́ tàbí olùtẹ́tisí. Ìwọ̀nyí ni èrò ìjìnlẹ̀. Ní ìbámu pẹ̀lú èrò Adébóyè (1969 & 2002) àti àwọn onímọ̀ mìíràn ti wọ́n gbà pé àkójọpọ̀ lítíréṣọ̀ alohùn Yorùbá jẹ́ èrò ọgbọ́n nípa ohun ti ó kánilára, ti a sì fi ohùn dídùn gbé jáde, yálà ní ìlànà ewì, ìsàré àti orin. A ṣe àmúlò òté ìtumọ̀ yìí pẹ̀lú àfikún ìmọ̀ pé gbogbo èrò ti a bá ti fi ojú ìhun ìjìnlẹ̀ wo ìṣẹ̀lẹ̀ àti àyíká rẹ̀, tí ó kọjá ìwòye léréfèé, tí a sì ṣe àgbékalẹ̀ èrò ọgbọ́n náà pẹ̀lú ìṣàmúlò ìpèdè ajúwe, yálà ní èyí ti a kọ sílẹ̀, ti a ká sínú fọ́nrán tàbí ti a fẹnu pọ̀ jáde fún ìtẹ́tísí ẹ̀dá abẹ̀mí, ni èrò ìjìnlẹ̀. Nítorí náà, ìtumọ̀ fí a fún erò ìjìnlẹ̀ nínú iṣẹ́ ìwádìí jẹ́ alákòóyawọ́ tí ó fún olùṣèwádìí ní ànfàání láti ṣe àmúlò gbogbo iṣẹ́ àtinúdá tí àwọn apohùn, tí a tún dà pè ní aláròjinlẹ̀ ẹ̀dá ti kọ lórin, léwì tàbí ṣe ní ìsàré. Ìwọ̀nyìí ní àwọn ààyè tí a tọ́ka sí fún ìṣàmúlò ìtúpalẹ̀ àgbékalẹ̀ ìwòye wa nínú ìlò oríkì ajẹmẹ́ranko àti àwọn Ìṣẹ̀dá abẹ̀mí mìíràn tí a ń yẹ wò.

## 4.3 Agbára Olódùmarè

Ìpèdè “Agbára” túmọ̀ sí ìkápá, tàbí àṣẹ láti lè ṣe ohun tí ó bá wuni láti ṣe. Fún àpẹẹrẹ, nínú ìrírí ẹ̀dá lágbàáyé, agbára jẹ́ ọ̀pá àṣẹ tí àwọn ọba, àwọn olóṣèlú àti àwọn aláṣẹ fi ń to ìlú. Agbára wà lára ohun tí olówó, ọlọ́rọ̀ fi lè ṣe ohun tí wọ́n bá fẹ́ sí tálákà. Bákan náà, agbára wà lọ́wọ́ ẹni tí ó ju ẹnìkejì lọ. Agbára ìbí wà lára ohun tí òbí fi lè ṣe àwọn nǹkan tí wọ́n fẹ́ lórí ọmọ tí wọ́n bí nígbà mìíràn (Ilésanmí, 2009). Kò sí ìyàn kankan lóri ta ni Olódùmarè jẹ́. Sí gbogbo ìṣẹ̀dá, yàlà abẹ̀mí tàbí èyí tí kò ní ẹ̀mí, Olódùmarè jẹ́ aṣẹ̀dá wọn (Mbiti, 1953). Nítorí náà, bí a bá ń sọ̀rọ̀ nípa Olódùmarè, òun ni ẹni tí wọ́n gbà pé ó ni gbogbo àṣẹ ìwàláàyè, àti ààyè àtilèṣe àwọn ẹ̀dá tí ó dá. Nítorí náà, bí a ṣe lo ìpèdè “Agbára Olódùmarè’ nínú iṣẹ́ ìwádìí yìí ni láti fi ipò àṣẹ, àti ojú ìwòye àwọn ẹ̀dá tí a ń ṣe àgbéyẹ̀wò (ìṣẹ̀dá abẹ̀mí àti àwọn ìṣẹ̀dá ajẹmẹ́ranko tí wọ́n wà lábẹ́ àṣẹ Olódùmarè), wo Olódùmarè, nípa ipò tí wọ́n to Olódùmarè sí; nínú ìlànà ìrònú wọn, ìṣe wọn, àti ìhùwàsí wọn.

## 4.4 Ìṣẹ̀dá Abẹ̀mí

Lábẹ́ àkọsílẹ̀ iṣẹ́ ìwádìí yìí, ìṣàmúlò ìpèdè “Ìṣẹ̀dá” túmọ̀ sí jíjẹ́ nǹkan kan, gẹ́gẹ́ bí i alààyè ènìyàn tí ó ń mí. Abẹ̀mí nínú ìwòye èrò ìjìnlẹ̀ túmọ̀ sí ohun tí ó lè mí nípa àbùdá ìwàláàyè ẹ̀mí ara nǹkan náà. Pàápàá tí Yorùbá bá pe ènìyàn ní ẹ̀dá, ó túmọ̀ sí ẹni tí Olúdá dá. Olúdá ayé àti ọ̀run si ni Yorùbá gbà pé o ṣe ìpìlẹ̀ gbogbo ẹ̀dá ohun tí ó ń mí, bí ènìyàn, tàbí ohun tí kò mí, bí i òkúta, nípasẹ̀ pé ohun náà kò ní ẹ̀jẹ̀ lára.

## 4.5 Ìlò Oríkì

“Ìlò” túmọ̀ sí bí àwọn ènìyàn àwùjọ ṣe ń ṣe àmúlò nǹkan kan si. Tàbí kí a sọ pé, bí nǹkan se máa ń wáyé lóòrèkóòrè sí. Ìpèdè “Oríkì” sì jẹ́ ọ̀rọ̀ kan tí a fi ń dá irúfẹ́ ọ̀kan pàtàkì lára lítíréṣọ̀ alohùn ìran Yorùbá mọ̀, yàtọ̀ sí àwọn ẹ̀yà lítíréṣọ̀ yòókù. ọ̀tọ̀lórìn bí orúkọ

olórúkọ ni ìpèdè oríkì jẹ́ láàrin àwọn lítírésọ̀ alohùn tí ìran Yorùbá ní. Bí Yorùbá ti ní orin, ìsàré àti ìsọ̀rọ̀kéwì tí ó jẹ́ abala mẹ́ta pàtàkì tí líltírésọ̀ Yorùbá lè gbà wáyé, ni oríkì jẹ́ orúkọ àkóyawọ́ tí ó lè hànde nínú ẹ̀yà mẹ́tẹ̀ẹ̀ta tí lítírésọ̀ lè gbà hù wáyé. Nítorí naà, lójú ìpèdè ìlò òríkì nínú iṣẹ́ yìí, àti ní ìbámu pẹ̀lú èrò àwọn onímọ̀ bi i Ògúndèjì (1991), tí ó gbà pé, "ó fẹ́rẹ̀ má sí ohun tí Yorùbá kò ní oríkì fun", jẹ́ kí a mọ̀ pé, nígbàkúùgbà ni a lè bá ìlò oríkì pádé nínú iṣẹ́ lítíresọ̀ ìran Yorùbá. Ògúndèjì (1991) so síwájú nínú èrò ìjìnlẹ̀ tirẹ̀ fún àpẹẹrẹ pé, "Yorùbá ní oríkì fún ikú, ewéko, orísìírísìí ẹranko, omi, òkè àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ".

## 5.0 Ìlò Oríkì àti Ìran Yorùbá

Bí a bá ǹ sọ̀rọ̀ nípa oríkì nílẹ̀ Yorùbá, oríkì ènìyàn ni ọkàn yóó sáré nàró mọ́. Ní èrò Ládélé (2008:166) oríkì jẹ́ ọ̀nà kan pàtàkì tí a fi ń dá ẹni tí ó bá jẹ́ ojúlówó ẹ̀dá Yorùbá mọ̀. Bákan náà, Bíòbákú (1973) fi yéni pé, kò sí ọmọ tí a bí nílẹ̀ Yorùbá tí kò ní oríkì. Ó tilẹ̀ sọ àsọyán èrò pé, oríkì jẹ́ kòṣe-é-mánìí fún ọmọ tí a bí ní sí àwùjọ Yorùbá.

> Throughout Yorùbáland, no child is given a name without also being given an oríkì, which is an important adjunct to any name. Oríkì could be described as a praise-name, cognomen, or nickname. It describes the child's character, or the circumstances of its birth, or what he or she is hoped to become. It may be given either at the time of the naming ceremony of the child, or later as a result of the child's subsequent development. The word oríkì is derived from Orí (head, or orígin) and kì (to cite), and so means, 'to cite one's orígin. (Bíòbákú, 1973:63)
>
> Nílẹ̀ káàárọ̀ oòjíire, a kì í fún ọmọ lórúkọ lái fún un ní oríkì, a máa ń sọ oríkì mọ́ orúkọ ni. Oríkì túmọ̀ sí oríyìn, àpèjẹ́ tàbí àlàjẹ́ orúkọ. Oríkì máa ń sàlàyé irúfẹ́ ìwà tàbí sàkání ibi tí a ti bímọ tàbí ohun tí ọmọ náà le ẹ̀ jẹ́ tàbí ohun tí ó lè dà lẹ́yìn wá ọ̀la. A lè fi oríkì fún ọmọ lọ́jọ́ ìsọmọlórúkọ rẹ̀ tàbí ká fún un nígbà tí a bá ń wo ìṣesí rẹ̀, bí ó ṣe ń dàgbà. Láti inú orí ni oríkì ti jẹ jáde. Àdàpè orí sì ni ìṣẹ̀dá. (Aáyan ògbùfọ̀ olùṣèwádìí).

Ohun tí àwọn àyọlò òkè yẹn ń kín lẹ́yìn ni ẹ̀rí pé, ìran Yorùbá ka oríkì sí pàtàkì. Èrò yìí kò yàtọ̀ sí ohun tí Akínyẹmí (1993) náà sọ. Àfíkún ohun tí a ń ṣàlàyé ni pé, bí oríkì ti wà fun ènìyàn, náà ni ìran Yorùbá ní oríkì wà fún àwọn ẹranko inú igbó, àti tijù. Lóòrèkóòrè sì ni àwon alátinúdá àti apohùn máa ń ṣàmúlò oríkì. Ìran Yorùbá ní oríkì fún àwọn ẹ̀dá iṣẹ́ ọwọ́ Olódùmarè míìran tí ó wà ní àyíká wọn. Ìran Yorùbá ní oríkì fún ìlú, bẹ́ẹ̀ ni wọ́n ní fún ìdílé kọ̀ọ̀kan. Oríkì wà fún àwọn akọni, àti àwọn ènìyàn jàǹkàn-jàǹkàn tí wọ́n ti làamilaaka nínú ètò ìdàgbàsókè, àti fún ìgbáyé-gbádùn ara wọn. Yorùbá ní oríkì fún ọba, ìjòyè àti àwọn òrìṣà wọn pẹ̀lú, gẹ́gẹ́ bí àkósílẹ̀ Adébóyè (2000) ti fi hàn. Gẹ́gẹ́ bí àbùdá kan tí ó ti fẹ́rẹ̀ di bárakú, bí ìran Yorùbá ṣe máa ń kíni fún gbogbo ìṣẹ̀lẹ̀, tí àwọn kan fi sọ ìran Yorùbá ní orúkọ (ìran Akú), nítorí pé ìlànà yìí hàn nínú ìlànà ìkíni wọn; bẹ́ẹ̀ náà ni a lè sọ pé ìran Yorùbá ní oríkì fún ohun gbogbo. Iṣẹ́ ìwádìí yìi fi idí ohun tí a sọ múlẹ̀ dan-in dan-in nítorí pé, orísìírísìí nǹkan ni àwọn apohùn nínú ìran Yorùbá gẹ́gẹ́ bí alárọ̀jinlẹ̀ lè ṣẹ̀dá oríkì fún.

## 6.0 Ìgbàgbọ́ Yorùbá, Ìṣàfihàn Agbára Aṣẹ̀dá nínú Ìlò Oríkì

Ohun tí a lè sọ nípa ìran Yorùbá pọ̀, pàápàá tí a bá ń sọ̀rọ̀ nípa ìwòye àwọn ìran náà nípa ìgbàgbọ́ nínú agbára ìṣẹ̀dá. Yorùbá gbàgbọ́ púpọ̀ nínú agbára, àti ìkápá ayé tí

Olódùmarè ní, tí ó fi ń darí ayé. Nínú èrò Mbíti (1969), èyí tí Àrèmú, et. al (2012: 283) fi hàn nípa ìhà tí àwọn ènìyàn àwùjọ Yorùbá kọ sí ẹ̀sìn wọn, àti àfihàn ìgbàgbọ́ nínú Olódùmarè. Ohun tí ó sọ nìyìí:

> *In Yoruba cosmology, man is believed to be at the center of the whole universe and created by the Supreme Being, God. Therefore, religion permeates every facets of life, and it is believed that religion is the strongest element that exerts probably the greatest influence upon the thinking and living of the people concerned* (Mbiti, 1969).
>
> Nínú ìwòye èrò ìjìnlẹ̀ àwọn Yorùbá, ìṣẹ̀dá ènìyàn wà láàrin gbùngbùn ayé, tí ó sì jẹ́ pé ìgbàgbọ́ wọn rọ̀ mọ́ ọ́n pé Olódùmarè tí ó ga jù lọ, ni ó ṣẹ̀dá ayé náà. Nítorí náà, ẹ̀sìn jẹ́ ohun tí ó ní ipa lórí gbogbo ìgbé ayé tí àwọn ènìyàn náà n gbé; bákan náà ni wọ́n gbà pé ẹ̀sìn ni ó lágbára jù, tí ó sì n kó ipa pàtàkì nínú ìròrí àti èrò ọ̀kan wọn. (Aáyan ògbufọ̀ Olùṣèwádìí)

Bákan náà Aremu, et. al (2012: 284) fi èrò (Mbiti, 1953) kín èrò wọn lẹ́yìn lórí ìhà tí awọn ènìyàn kọ sí ẹ̀sìn ìbílẹ̀, nígbà tí wọ́n sọ pé:

> *Religion is therefore always with the people most especially among the rural communities "because their life is closely tied to the land and to the traditional culture"* (Aremu, et. al (2012: 284).
>
> Ẹ̀sìn jẹ́ ohun àsúnmọ́ àwọn ènìyàn, pàápàá gbogbo àwọn ará ìlètò, nítorí pé, ìgbé ayé àwọn ènìyàn náà so mọ́ ẹ̀sìn, àṣà àti pé, ìgbàgbọ́ wọn rọ̀ mọ́ ẹ̀sìn ìbílẹ̀ wọn. (Aáyan-ògbufọ̀ Olùṣèwádìí)

Pẹ̀lú Ìwòyé Mbiti, ó jẹ́ kí a mọ̀ pé ẹ̀sìn, àṣà àti ìgbágbọ́ àwọn ìran Yorùbá ṣòro láti yà, páápàá_tí ìgbàgbọ́ wọn so mọ́ ẹ̀sìn ìbílẹ̀ wọn. Bákan náà ni wọ́n tún gbàgbọ́ pé Olódùmarè (tí ó ni agbára ìṣẹ̀dá, tí wọ́n ń dà pè ní Aṣẹ̀dá), tún yọ̀nda ìmọ̀ tí ó tayọ ti ẹlòmíràn fún àwọn ìsọ̀rí ẹ̀dá kan, tí a pe ní "abonìyàn" lọ́nà àrà ọ̀tọ̀. Èrò nípa kíkó agbára-lé-abonìyàn lọ́wọ́ tí Yorùbá gbàgbọ́ nínú rẹ̀ tún jẹ́ àpẹẹrẹ kan pàtàkì, àti ìdí tí àwọn apohùn tàbí ojúlówó ọmọ Yorùbá fi máa ń ṣe àfihàn ìgbàgbọ́ wọn nínú ìṣẹ̀dá abonìyàn tí a ń pè ní "Ìyà mi" tàbí "Àjẹ́". Ìdí àfihàn oríkì àwọn "Ìyà mi" nìyìí, nínú èrò ìjìnlẹ̀ Yorùbá gẹ́gẹ́ bí i alábùdàá ìṣẹ̀dá pàtàkì láti òde-ọ̀run wá, tí Olódùmarè fún ní alágbára ọ̀tọ̀lórìn. Àkíyèsí ni pé, nígbà tí àwọn apohùn bá ń ṣe iṣẹ́-ọnà àtinúdá nínú ìlò oríkì fún "Ìyà mi" / "Àjẹ́", yàtọ̀ fún pé wọ́n máa ń júbà àwọn ìsọ̀rí ẹ̀dá yìí, àwọn apohùn tàbí akéwì láwùjọ eré orin máa ń jẹ́ kí àwùjọ mọ irú agbára àṣẹ tí Olódùmarè fún wọn. Èyí sì máa n hàn nínú ọ̀kẹ́ àìmọye orúkọ àti òrìkì tí wọ́n ń ṣẹ̀dá fún wọn.

Àjàyí àti Ajíbádé (2021:210) gbà pé, oríkì jẹ́ ká mọ òtítọ́ tí ó dájú nípa àwọn ẹranko nítorí pé ó fi ìṣesí, ìhùwàsí àti ìrísí àwọn ẹranko náà hàn. Adébáyọ̀ (1974:vi) náà gbà pé, "ẹnu àwọn baba wa nìkan ni a ti lè gbọ́ àwọn oríkì wọ̀nyìí, (ìyẹn oríkì ajẹméranko) lóde-òní". Pẹ̀lú ìwádìí wa, kò sí àní-àní pé ìran Yorùbá ní oríkì fún gbogbo ìṣẹ̀dá ajẹméranko. Nítorí náà, nínú iṣẹ́ yìí ni a ó ti tanná wo díẹ̀ lára oríkì àwọn ẹranko kọ̀ọ̀kan tí ó jẹ mọ́ àfojúsùn àkòrí iṣẹ́ yìí. A ó sì pín àwọn ìṣẹ̀dá ajẹméranko náà sí ìsọ̀rí, lábẹ́ èyí tí a ó ti wo oríkì mẹ́ta-mẹ́ta ní abẹ́ ìsọ̀rí kọ̀ọ̀kan fún àtúpalẹ̀.

## 7.0 Ìpínsísọ̀rí Àwọn Ìṣẹ̀dá Abẹ̀mí tí Olódùmarè dá

A pín ìsọ̀rí ìṣẹ̀dá ohun tí Olódùmarè dá sí ọ̀wọ́ mẹ́rìn fún àkóyawọ́ àlàyé kíkún.

**7.1. Ọ̀wọ́ kìn-ín-ní ni:** ọ̀wọ́ ẹ̀dá ènìyàn, tí ó jẹ́ takọ-tabo. Láwùjọ ìran Yorùbá, gẹ́gẹ́ bí a ti ń rí wọn ní àwùjọ mìíràn, ẹ̀dá ènìyàn lè jẹ́ ọ̀kùnrin tàbí obìnrin. A lè mọ̀ ìyàsọ́tọ̀ àwọn ìsọ̀rí ẹ̀dá ènìyàn wọ̀nyìí nípa ìrísí, ìṣesí àti àbùdá káríayé, tí Olódùmarè dá mọ́ ìṣẹ̀dá akọnìyàn tàbí abonìyàn. Bí ó tilẹ̀ pé àwọn abo tàbí akọ ìṣẹ̀dá mìíràn máa ń gbìyànjú láti ṣe bí i ìdàkejì ohun tí Olódùmarè fi wọ́n dá ní àrà, síbẹ̀, ìyàtọ̀ tí ó hànde wà láàrin abo tàbí akọ ẹ̀dá ènìyàn, tàbí ẹranko. Àpẹẹrẹ àwọn ìsọ̀rí ẹ̀dá wọ̀nyìí ni ènìyàn tí ó lè jẹ́ ọkùnrin, tàbí obìnrin, tí ó ní ọpọlọ láti ro àròjinlẹ̀ èrò, tí ó sì n mí; tí omi, isan àti ẹ̀jẹ̀ wà nínú ìṣẹ̀mí rẹ̀. A gbà pé ènìyàn tí ó ní àbùdá ìtàyọ ni "Ìyà mi" wà. Nítorí nàá, a ó ṣe àmúlò oríkì Ìyà mi nìkan fún ìtúpalẹ̀. Oríkì wọn nìyìí:

Oríkì Ìyà mi (Alágogo Idẹ)

Afínjú ẹyẹ
Ìyàmi Ọ̀dúndúnladé,
Obìnrin kúkurú rẹ́gírẹ́gí
Àwọn tí n lọ nígbà ọjà bá tú
Ìyà mi ẹlẹ́wù osùn,
Ẹlẹ́wù ẹfun,
Aláṣọ aró,
Ẹyẹ sóóró mọ̀gà.
Ẹyẹ mọ̀gàmọ̀gà sorò
Akéroro
Olóhùn roro
Ololá Ààjìn
Olókìkí òru
O-lànà màrin-màrin
Orí kíkún tíkò níná
Ọjà kíkún tí-kò-lérò
Olóbò a-kì-í-dó
Anídọ a-kì-í-fọwọ́-pà
Mìnì jọ̀jọ̀
Ìgbín onírun Àjẹ̀njẹ̀tán
Akọ Ajá Aborí-gbóngbó
Ológìnní abìrù-gìlọgìlọ
Ẹyẹ abapá wíni
Ẹyẹ abẹsẹ̀ wíni
Ẹyẹ abìnrìn àrà lẹsẹ̀ méjèèjì
Òkìkí ọlá-afòru-lálú
A-ságaara, A-rìngaara
Àlùbọ́sà obìnrin
Gìirìgìirì dá
Ìdàndágìirì
Afẹnu gbobì-lọ́gànjọ́
Akáyínsoró
A-tobò-soró
A-fúyé-gẹngẹníyẹ̀ẹ́
Akọ ajá abòru-mẹ́rin
Akọ ajá abòru-mẹ́jọ
Abo ajá abòru-mẹ́rìndínlógún
Olójòǹgbòdú obìnrin ikú,
Igúnnugún tí í bàlẹ́ a-jorí
Àkàlà balẹ̀ a-jẹ̀dọ̀
Ọlákàtá

Ọláràká
Ọlátàká ràgbàdà
Ìyàmi ọlọ́jà mẹ́rìndínlógún
Oníbàntẹ́ pèlènjà
Anamọ-naye
Ọlọ́fun-Àásán
Oníkùn-àsè
Ìyàmi òsòròmònìgà
Apani má hàgún ún
Ọ̀papara
Ọ̀kan hì, hì, hì
Afọ̀ọ́kán-nà-mú
Atapájorí
Atìfunjẹ̀dọ̀
Ajẹ̀dọ̀ ènìyàn má-bì
Adélé dolú
Èrò dọ́nà dosù
Oníyẹ̀ ọ̀wẹ̀wẹ̀
Àgù-àlà-mosù
Ọlọ́yùn-ún-bẹ́rẹ́ abìrùgbọọrọ
Ọláporó
Ọlákìígbó
Dángiri
Ọ̀tẹlẹ̀-kílẹ̀-mì
Ọ̀tẹlẹ̀-kílẹ̀-rọ́ gbàdàgbàdà
Omí nlá abojú na-n-gun
Ìyà mi onígbà ẹyẹ.
Aláwòdì
Olówìwí
Alápàńdẹ̀dẹ̀ ẹyẹ àgbààgbà.
Ìyà mi ẹlẹ́yẹ agbe
Olódídẹrẹ́ Ìwó
Ẹyẹ ò-sòròmọ̀gà
Ẹyẹ mọ̀gà-mọ̀gà sorò

Olómi tééré omi ayé
Olómi tààrà omi ilẹ̀
Onílé máwọ̀máwọ̀
Arógbà Aṣọ-má-balẹ̀
Ọ̀-ránni níṣẹ́ fàyà tíì
Ọsá méjì
Ológbò dúdú-èse
Ológbò láàjìn
Ògbórí igi ké han an, han an, han an.
Ò-jẹ̀gún-òṣìkà
Alágogo lékúlékú
Òpìkí ẹlẹsẹ̀ osùn
Olójú-ọ̀mọ̀ràn lórita.
Apani-máyọdà
Oníyẹ̀ẹ́ Abàmì. (Àtinúdá Fálẹ̀yẹ, 2024)

**7.2 Ìsọrí ọwọ́ kejì**: Àwọn ìsọrí ẹdá wọnyìí ni àwọn abẹmí tí wọn jẹ́ ẹranko inú igbó. ṣùgbọn abala méjì ni àwọn wọnyìí pín sí. Àwọn ìsọrí àkọ́kọ́ ni àwọn ẹranko tí àwọn ènìyàn ń ṣe àmúsìn wọn nínú ilé, àti àwọn ìsọrí ẹranko abánígbé àyíká, tí ènìyàn kò sìn. Lára àwọn ẹranko tí a ní lọ́kàn lábẹ́ ìsọrí yìí ni àwọn tí wọn lè jẹ lórí ilẹ̀, bí i: ewúrẹ́, adìyẹ, ajá, ẹyẹlé, àgùntàn, ológbò, ẹsin, ìgbín àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Àwọn tí a kì í sìn, ṣùgbọn tí wọn ń báni gbélé ní àyíká ni: èkúté, eku (onírúurú), ẹmọ́, ọ̀yà, ẹ̀fọn, agbọ́n, ìgalà. Lára àwọn ẹranko wọnyìí, ni a rí àwọn èyí tí ó lè jẹ lórí igi bí i ọ̀bọ. Fún ìwọ̀nba ààyè tí a ní nínú bébà yìí, a ó ṣe àmúlò oríkì Ewúrẹ́, Ajá, àti Olóńgbò nínú àwọn ẹranko tí ènìyàn ń sin. A ó sì ṣàmúlò oríkì tàbí àròfọ̀: Agbọ́n, Eku àti Ẹ̀fọn gẹ́gẹ́ bí ìsọrí ẹranko abáni-gbélé tí ẹ̀dá ènìyàn kì í sìn.

## 7.0 Àkójọ Oríkì àti Àlàyé Ìtúpalẹ̀

### 7.1 Ẹranko Abánigbélé tí a n sìn

Oríkì díẹ̀ lára àwọn ẹranko tí a tọ́ka sí pé ìṣẹ̀dá ènìyàn máa ń sìn nínú ilé ni a ó máa wo àròfọ̀ tàbí oríkì wọn fún àtúpalẹ̀ báyìí.

**7.1.1 Ewúrẹ́:** Gẹ́gẹ́ bí àkíyèsí ìṣe àti ìhùwàsí Ewúrẹ́, ó jẹ́ ẹran(ko) tí ó tún ní ànfààní àmúsìn, láti bá ènìyàn gbé ilé fún ọ̀pọ̀lọpọ̀ ìdí. Ewúrẹ́ ní ànfààní láti bí ọmọ nítorí pé àbùdá takọ-tabo ni Olódùmarè fún un. Abo àti akọ ewúrẹ́ wà, gẹ́gẹ́ bí Olódùmarè ṣe gbé àgbára ìbísí fún ìṣẹ̀dá rẹ̀. Ìṣẹ̀dá ènìyàn sì máa ń sin ẹran(ko) yìí fún ọ̀nà láti di ọlọ́là. Yàtọ̀ sí títà, àwọn ènìyàn máa ń pa ewúrẹ fún (oúnjẹ) ìjẹ ní àkókò ìnáwó, fún ìbọ Ifá àti ètùtù mìíràn, ti yóò fi rọ̀ wọ́n lọ́rùn. Ewúrẹ́ máa ń jẹ́ àmúlò fún àwọn ènìyàn nípa pé wọn kì í ṣẹ̀ṣẹ̀ máa wá owó láti ra ẹran fún àṣè nígbà ìnáwó wọn. Àkíyèsí mìíràn ni pé, Itú (akọ ewúrẹ́) máa ń ní oríkunkun ju abo ewúrẹ́ lọ, bóyá nítorí pé ó jẹ́ abo. Ìdí nìyí ti ó fi jẹ́ pé àwọn alárọ̀jinlẹ̀ máa ń fi ènìyàn wé ẹran(ko) yìí bú, pàápàá tí irú ẹ̀dá bẹ́ẹ̀ kò bá gbọ́ràn sí àgbà tàbí òbí rẹ̀ lẹ́nu. Ìdí nìyìí ti Yorùbá fi máa ń pàrokò fún ọmọdé tàbí ènìyàn ti wọ́n bá fẹ́ bú pé:

Alàìgbọran, abeti-dídi bí itú (akọ ewúrẹ́).

Bákan náà, ìpèdè ẹnu ifá yìí:

Itú dúdú ní í ṣọkọ ewúrẹ́ 1.
Àgbò-mọ̀mọ̀ ní í ṣe ọkọ ìlágùntàn… 2.

Ìlà kìn-ín-ní (1) nínú àfàyọ òkè yẹn jẹ́rìí sí èrò ìjìnlẹ̀ pé Olódùmarè gbé agbára ìṣẹ̀dá ṣíṣe (jíjẹ́) abiyamọ (ìyàwó) fún abo ewúrẹ́, nígbà ti akọ (Itú tí ó jẹ́ akọ ewúrẹ́) máa n ṣe ìṣe ọkọ.

Nínú gbajúgbajà àròfọ̀ ẹnu Yorubá yìí:

Ẹran Ewúrẹ́ jẹ ẹran ilé,
Tó máa ń jìyà púpọ̀
Nítorí àìgbóràn rẹ̀.
Bí wọ́n bá ná Ewúrẹ́
Á gbọntí méjì pẹ́pẹ́,
kólójú tó séjú pé ẹ́,
Á tún padà síbi tí,
Ó ti jìyà lẹ́ẹ̀kan.
Ẹ̀yin ọmọde ẹ gbọ́,
Ẹ má ṣe bí Ewúrẹ́.
Ẹran alàìgbọràn.



Akéwì jẹ́ kí a ní òye irú ìgbàgbọ́ ti Yorùbá ní sí ewúrẹ́ gẹ́gẹ́ ohun ọ̀sìn. Ìlà kejì sí ìkẹta (2-3) fi ìhùwàsí ẹran tí ìṣẹ̀dá ènìyàn sọ ní orúkọ ewúrẹ́ hàn, pẹ̀lú agbára ti alámùúnsìn rẹ̀ ní láti fi ìyà jẹ́ ọ̀sìn náà. Pàápàá, nígbà gbogbo tí ó bá ti ṣe àìgbọràn.

**7.1.2 Ajá:** Bákan náà, Ajá ní àbùdá ìbísí gẹ́gẹ́ bí i ti ènìyàn. Takọ-tabo ni. Àmọ́ bí ìran Yorùbá tàbí òbí bá bú ènìyàn nípa lílo ìpèdè: "ọmọ lásán, èkejì Ajá" fún ènìyàn, kì í ṣe

ìpèdè tí ó dára rárá. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé Ajá, gẹ́gẹ́ bí ẹran ilé wúlò púpọ̀ fún ìsọ́, iṣẹ́ ọdẹ (láti pa ẹran, tàbí láti fi ojú olè hànde nípa gbígbó), àti ààbò mìíràn; síbẹ̀, ìwà ọ̀dọ́kọ tí Ajá máa ń hù kì í jẹ́ kí ènìyàn fi ojú rere wo irú ìpèdè àbùkù bẹ́ẹ̀. Lára àkíyèsí ìhùwàsí Ajá ní àwùjọ, ìṣesí ẹranko náà, àti àbùdá tí Olódùmarè dá mọ́ Ajá ni Odúnjọ (2018) ti ṣẹ̀dá ìpèdè àṣàyàn láti ṣẹ̀dá oríkì fún ẹ̀dá ẹranko náà. Ó ní: Ajá

(A) Ajá lẹran inú ilé
Tó létí méjì sagada.
Ó tún nírù tó gùn gbọọrọ
Gbígbó ni igbe ajá
Ajá sì tún gbóòórùn gidi.
Eré àṣádijú ń bẹ lẹ́sẹ̀ rẹ̀.
Oríṣìíríṣìí nǹkan níí fií ṣoúnjẹ.
Egungun lóyàn láàyò.
(Ọdúnjọ, 2018)



(B) A le fajá sọdẹ ilé;
A le fajá sọdẹ oko
A ń fajá mólè láwùjọ ìgbàlódé
Òyìnbó ń rán ajá lọ́jà
Wọ́n sì fi ń darí ẹni ràjò
Ajá wúlò púpọ̀.
Ẹ tún gbọ́, Ajá lAjá Òyìnbó
Ajá Òyìnbó dára púpọ̀, ó wù mí
Ṣùgbọ́n ó ku àtitọ́jú bí ọmọ.
Ajá òyìnbó dára pẹ̀lábùkù rẹ.

Ọ̀rẹ́ àtàtà tún lajá jẹ́ nínú ẹranko
Bí ìjàǹbá bá ń bọ̀, tàbí bí ìjàǹbá bá sún mọ́ni tán
Ajá ń gbani lọ́wọ́ ibi àìròtẹ́lẹ̀
Kódà, Ajá moore ju ọmọ ẹlòmíràn lọ,
Ajá a máa sọpẹ́ oore.
Ọ̀rẹ́ lajá, ọ̀rẹ́ ènìyàn. (Fálẹ́yẹ, 2024)

Àbùdá ènìyàn ni gbígbé inú ilé. Bẹ́ẹ̀ sì ni, etí méjì, ẹsẹ̀ méjì ni ẹ̀dá ènìyàn ń ní. Ìwòye wa ni pé, bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé ìyàtọ̀ wà láàrin ènìyàn àti ẹranko, àkíyèsí tí Akéwì ń pè wá sí ni àfihàn àfijọ ìrísí tí Ajá ní pẹ̀lú ènìyàn:

Ajá lẹran inú ilé
Tó létí méjì ṣagada.

Àbùdá ìwúlò tí Ajá ni sí ènìyàn ni ìlà (3) kẹta sí ìlà (6) kẹfà ń tọ́ka sí. Ìlà kẹfà tilẹ̀ ṣí èrò náà lójú pé: Ajá wúlò púpọ̀.

Ìpèdè àmúlò nínú òríkì yẹn ń sọ pàtàkì àti ojúṣe ẹranko yìí sí ènìyàn. Bí a bá wo ìlà (11) kọkànlá sí ìparí ewì Fálẹ́yẹ (2024), apohùn náà jẹ́ kí a mọ̀ pé, ọ̀rẹ́ àtàtà, bí i ẹ̀dá ènìyàn tí a lè yàn lọ́rẹ̀ẹ́ ni ajá nínú ẹranko. Lára ojúṣe tí ẹranko náà ní sí ènìyàn ni àfihàn ìṣe Ajá tọ́ka sí nínú oríkì náà; pàápàá bí ẹranko bá rí ìtọ́jú. Ajá a máa pa olùsìn rẹ̀ mọ́ nínú ìjàǹbá, tàbí kí ó ṣòfófó ìṣẹ̀lẹ̀ fúnni. Abájọ tí Apohùn náà ṣe fún Ajá ní oríkì: “Agbani-lọ́wọ́-ibi-àìròtẹ́lẹ̀”.

Lára àkíyèsí tí àwọn alátinúdá máa ń ṣe náà ni ṣíṣe àfihàn ìhùwàsí ẹ̀dá nígbà tí wọ́n bá ń hun oríkì fún ìlò láwùjọ, Akéwì náà sọ pé: "Ajá moore ju ọmọ ẹlòmíràn lọ, nítorí pé:

Ajá a máa sọpẹ́ oore.
Ọ̀rẹ́ lajá, ọ̀rẹ́ ènìyàn.

**7.1.3 Olóńgbò:** Àpẹẹrẹ kẹta tí a fi ṣe àwòta ìjìnlẹ̀ èrò nípa agbára àwọn ìhùwàsí kan tí Olódùmarè gbé wọ inú ẹranko abánigbélé ni àwòmọ́ ẹranko tí a mọ̀ sí Olóńgbò. Ẹ jẹ́ kí a wo oríkì rẹ̀: **Olóńgbò**



Bó bá wu ajá kó wọ agbádá iná.
Bó bá wu Àmọ̀tẹ́kùn kó wẹ̀wù ẹ̀jẹ̀.
Olóńgbò ló làdàpè tí gbogbo wa ń pè lólógìnní.
Bólógìnní sán àkísà mọ́ ìbàrá ìdí
Ẹgbẹ́ apẹranjẹ ní í ṣe lágbo.

Olóńgbo ló lè dènà dèjà,
Bó bá rọra húkọ́ ìjà lásán
Eku kéékèèkéé, Eku nínlá-nínlá
Tó bá gbọ́ kíké Olóngbò
Yóó tọ̀tọ̀ ojo.

Bẹ́ẹ̀ ni, ẹ jú Olóńgbò sókè nígbà igba
Èèwọ̀ ni, ẹ̀yìn Èse kì í kanlẹ̀.
Irun Ológbò ò gbọdọ̀ kó síni lọ́fun,
À fẹni bá fẹ́ húkọ́-fée.

Gbogbo Eku tó lórúkọ nílé kóra wọn jọ
Lógún lógún, nígba nígba
Wọ́n ń pé bìiròkòtò, wọ́n fẹ́ tẹ́
Wọ́n ń ṣẹ́ gègé ọ̀tẹ̀,
Wọ́n ní wọ́n fẹ́ pOlóńgbò lẹ́nu mọ́.
Àjò tÓlógìnní rè
Ló mékú ilé gbìmọ̀ràn ọ̀fò lẹ́yìn àgbà ọdẹ.
Ijọ́ tọ́kọ Eku dé,
Gbogbo Eku ilé ló sùn nínú ẹ̀jẹ̀.
Ológìnní, a réèkán-ná-dádé
Ẹran tó feyín ṣègbè lẹ́yin Eku,
Ológìnní ò ní í yé dọdẹ Eku
Àìtètèwọ́n Olóńgbò nìkàn ní í jìyà. (Àtinúdá Fálẹ́yẹ, 2024)

Àròfọ̀ oríkì nípa Olóńgbò òkè yìí ló ṣàfọ̀mọ́ ohun tí àwùjọ tún ń da ẹranko náà pè: Ológìnní àti Èse. Bóyá nítorí ìrìnsí rẹ̀ ni Yorùbá ṣe pè é ní orúkọ yìí. Ohun tí oríkì máa ń ṣe náà ni láti júwe ẹ̀dá nípa ìrísí, ìṣesí àti àbùdá ìdámọ̀ àti èèwọ̀ rẹ̀ tí ó fi yàtọ̀ sí ẹlòmíràn. Fún àpẹẹrẹ, Fálẹ́yẹ, (2024) fi èèwọ̀ Olóńgbò àti àbùdá rẹ̀, bí àṣẹ Olódùmarè lára ẹranko náà hàn nígbà tí ó ní:

…Èèwọ̀ ni, ẹ̀yìn Èse kì í kanlẹ̀.
Irun Ológbò ò gbọdọ̀ kó síni lọ́fun,
À fẹni bá fẹ́ húkọ́-fée.

Nínú oríkì yí náà ni a ti rí òfófó tí apohùn ṣe nípa orúkọ mìíràn tí Olóńgbò ń jẹ́: "Ẹgbẹ́ apẹranjẹ". Ìpèdè tí apohùn lò nínú oríkì yìí fún wa ní òye pé agbára ìṣọdẹ wà tí

Olódùmarè gbé wọ ẹranko náà bí i ti Ajá àti Àmọ̀tẹ́kùn tàbí kọ̀lọ̀kọ̀lọ̀ tí wọn jọ ń pa ẹran mìíràn jẹ. Bákan náà, oríkì Olóńgbò ṣàfihàn agbára tí ẹranko náà ní lórí Eku.

**7.2 Ìṣọ̀rí Ẹranko tí a kì í sìn, ṣùgbọ́n tí wọ́n ń báni gbélé:** Ìṣọ̀rí àwọn tí a kì í sìn ni a ó wo oríkì wọn báyìí. Ó dájú sáká pé ẹ̀dá ènìyàn tí ó ní ìwà rere kò ní í fẹ́ sin agbọ́n nítorí ìṣe òmùgọ̀, àti ìhùwàsí àgbọ́n-foro rẹ̀. Ìwà ìkà rẹ̀ sí ènìyàn, sì kúrò ní kékeré.

**7.2.1 Agbọ́n:**



Ọgbọ́n àgbọ́njù ló kó bÁgbọ́n
BÓyín ṣe ń soyin
Là bá ṣe fún Agbọ́n.
Àmọ́ ìmọ̀ àmọ̀jù ló kó bÁgbọ́n
Agbọ́n gbọ́n.
Agbọ́n gbọ́n àgbónju ju ẹni tí wọ́n ní kó kọ́ ọ nísẹ́ lọ
Agbọ́n kò farabalẹ̀, Agbọ́n kò gbẹ̀kọ́
Afárá oyin síṣe bá dojútì fómùgọ̀.

Inú igbó ló yẹ kÁgbọ́n ó ti máa soyin
Ìtìjú ló mÁgbọ́n sérí wálé
Agbọ́n sérí wálé tán,
Ó dolóró tanitani.
BÁgbọ́n bá fẹ́ soro á tìdí bọlé.
Oyín gbọ́n, Oyín kọ́gbọ́n mọ́gbọ́n,
Agbọ́n gbọ́n jọlọ́gbọ́n lọ́
Ọgbọ́n Agbọ́n tán sì wá dòmùgọ̀.

Agbọ́n kì í dédé tani
Ẹní bá fín Agbọ́n níràn ní í bínú sí
Ìsèdàá tó gbọ́n, tó solé Agbọ́n mọ́rí
Agbọ́n ta alágbọ̀n nígbà tó gàgbọn
Agbọ́n ìsàlẹ̀ lóni hóhùhóhù.
Ẹní Agbọ́n bá bínú sí
N lAgbọ́n n ta
Ẹni ayé bá fẹ́ ẹ́ bá jà ni wọ́n n fagbọ́n ta.
Ayé e má ta mi o,
Bẹ́ ẹ bá dagbọ́n, ẹ má ta mi
Bẹ́ ẹ bá dagbọ́n
Ẹ má fàìgbọ́n bá mi jà ní kọ̀rọ̀.

**7.2.2 Eku**



Mélòó la fẹ́ kà nínú eku ilé?
Mélòó ni ká kà nínú eku òde?
Mélòó leku tá a fẹ́ mú nínú eku ti n bẹ lóko?
Òkan leku asín jẹ́
Nínú Eku tó gbalé tó gboko.
Se bí eku ẹmọ́ tún n bẹ?
Eku olósè n kọ́?
ọba leku ẹdá bí a bá n dárúkọ gbogbo eku.
Ilé lékuléja la ti lè mọye eku tó wà láyé
Òdò àgbà ọdẹ ìṣègùn la ti lè mọye eku tó wà níjù,

TÓlúdá ayé fi tanú igbó lọ́rẹ
Pé kí gbogbo eku máa yan fanda
Kí wọ́n máa bí sí i, kí wọ́n ó sì máa pọ̀ láyìíká gbogbo.

Ọ̀kan leku tún leku ẹ̀lííri
A kìí kánjú tulú ọrán
Igba eku kò kún kòkò bó bá dọ̀rọ̀ àtiyanjẹ.
Olóròógbò leku
Bó bá bọ́ sọwọ́ ológbo, á ta ka-n-ka
Ìwà ìkà ń bẹ lọ́wọ́ eku ilé gbogbo.
Wọ́n ń jaṣọ, wọ́n sì le bàwé jẹ́.
Ekú ti jẹ ìwé ẹ̀rí Alákòwé rí
TÁlákòwé sì dalákorí lọ́wọ́ ọsẹ́ téku ṣe!
Eku ti túlé lọ́kọláya
Tó jèwé ẹ̀rí ìgbeyàwó,
Táya dalákora alàìkíyèsí lówó ìjoba
Lákòókò àyẹ̀wò ìwé ẹ̀rí fún iṣẹ́!
Eku ni jélé-jele
Eku ni jẹ̀wéjẹ̀wé tí kò ránni-nísẹ̀
Eku ò lóun ẹkò bàlú jẹ́.
Ọpẹ́lọpẹ́ Ológìnní tí kò gbà fun ún,
Àmọ́ gbogbo eku kọ́ ló burú
Gbogbo eku kọ́ ló ṣe é jẹ!
Eku Olósè ṣe é pàrokò ẹ̀bẹ̀ fágbà.
Eku ẹmọ́ a máa dùn lọ́bẹ̀ jọjọ.
Aṣẹ̀dá ló feku tani lọ́rẹ
Àrà ló fi wọ́n dá sáwùjọ gbogbo ìṣẹ̀dá. (Fálẹ́yẹ, 2024)

7.2.3 **Ẹ̀fọn:** Bákan náà, Ẹ̀fọn jẹ́ ẹranko kékeré tí a ń rí ní àyíká ìsọ̀rí àwọn ọ̀wọ́ kìn-ín-ní ìpínsísọ̀rí ti a ṣe, ṣùgbọ́n ìrísí, ìhùwàsí àti èrò àwùjọ ẹ̀dá ènìyàn náà ni Fálẹ́yẹ (2024) ti ó ṣe àhunpọ̀ oríkì fún ìṣẹ̀dá yìí ṣe àfihàn.

**Ẹ̀fọn**



Bíntín lẹ̀fọn,
Ẹ̀fọn le múni gbára ẹni létí.
Takọtabo lÓluwa Ọba dáyé,
Takọtabo lOlúwa Ọba dá wọn fún wa.
Akọ Ẹ̀fọn ń bẹ níbẹ̀ tí ò le,
Abo Ẹ̀fọn burújài wọ́n ń ṣèkà!
Akọ Ẹ̀fọn wọn kì í jẹ ni,
Àmọ́ kíké wọn
Kò ní i jéèyàn ó sùn bó bá fẹ́
Ó le mú takọtabo wọ̀yáàjà
Ogun gbígbára ẹni létí le súyọ
Bẹ́ẹ̀ bá rẹ́ni to láìsàn ibà,
Ẹ wádìí dọ́dọ̀ abo ẹ̀fọn.
Àpọ̀jù Ẹ̀fọn ń ṣe wá níbi ní dúnníyàn,
Àpọ̀jù takọtabo Ẹ̀fọn kò seni lánfàání níbi
Atá kéré ọkọ ojú lata ń ṣe;
Ẹ̀fọn lè kéré, iṣẹ́ ọwọ́ Ẹ̀fọn ò kéré
Tàgbà tọmọdé
N lẸ̀fọ́n ti tipa ibà rán rọ̀run

Ẹ̀fọ́n ń han Adúláwọ̀ léèmọ̀. (Àtinúdá, 2024)

### 7.3 Ìsọ̀rí Àwọn Ẹranko Ìṣẹ̀dá inú Omi

**Ìsọ̀rí ọ̀wọ́ kẹta**: Àwọn tí a pín sí abẹ́ ìsọ̀rí yìí ni ìṣẹ̀dàá etí omi àti inú omi. Etí omi tàbí inú omi ni àwọn ìṣẹ̀dàá náà ń gbé, tí wọ́n ti ń ṣe ọlá tí Olódùmarè yọ̀ndà fún wọn. Àwọn ìṣẹ̀dá inú omi yìí náà ní ìsọ̀rí takọ-tabo. Nítórí náà, a lè rí èyí tí ó lè jẹ́ akọ, tàbi abo bí i ti ènìyàn, tí àwọn náà ń ṣe àmúlò àbùdá abiyamọ. Àpẹẹrẹ àwọn ìsọ̀rí abẹ̀mí wọ̀nyìí ni: Ẹja (onírúúrú), bí i aborí, àrọ̀gìdìgbà, ọ̀nì, àǹtà, kọ̀nkọ̀, ọ̀pọ̀ló, àkèré àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. A ó lo Ẹja, Ọ̀nì, àti Kọ̀nkọ̀ fún àtúpalẹ̀.

**7.3.1 Ẹja**: Ọ̀kan pàtàkì ni àwọn ìsọ̀rí abẹ̀mí inú omi ni Ẹja jẹ́. Sí ọmọnìyàn, ànfààní ńlá ni ìwàláàyè ẹ̀ja àti àwọn ẹ̀dá inú omi, nítorí pé ènìyàn ń fi Ẹja ṣe oúnjẹ. Kódà, ìgbàgbọ́ ni pé nítorí ẹ̀dá orí ilè ni Olódùmarè ṣe ṣẹ̀dá àwọn òwó tí ó wà nínú omi. Àkíyèsí ni pé Ẹja kò lè ní àlàáfíà tí ó bá ti kúrò nínú omi tí í ṣe ibùgbé tí Olúdá ayé àti ọ̀run dá a sí. Inú ibú omi ni àwọn ti ń yan, tí wọ́n ti ń bí, tí wọ́n sì lè gbé ayé ìrọ̀rùn. Ẹ wo oríkì **Ẹja:**

**Ẹja**
Ẹja lónibú
Inú igbó la mọ̀ tẸ́ku ń gbé.
Bá a ṣe dẸ́ja tán ladómi
Ìṣe Eku, ìṣe Ẹja wọ́n yàtọ̀ sí ra
Ìṣe ẹ̀dá gbogbo ló sỌ̀tọ̀ọ̀tọ̀.



Ẹja lẸja ń jẹ sanra,
BẸ́ja bá wá ń gbẸ́ja mì lódò bíi tì Ganniкú kọ́
Ẹja tó ń bẹ lomi pọ̀ rẹpẹtẹ,
Èmi ò rò pé wọ́n lóǹkà
Alagbalúbú lẸja tó n bẹ lómi
Abìwẹ̀ gbàdà tó ń jọlá omi wọ́n pọ̀ lódò.

Eku ń jọlá igbó, Ẹja ń jọlá omi,
Ẹyẹ ń jolá tiẹ̀ ó ń fò kiri
Ẹja lónibu
Ọmọ Ẹja ló ninú omi
Ẹ̀dá tó ń bẹ lódò tó ń bẸjá gbé
Wọ́n pọ̀, wọ́n pàpọ̀jù.
Omíṣadé, Omíṣoore, Omilaní,
Gbogbo ọmọ adáríhúnrun tó ń bómi jóruko;
Ta ló le wẹdò bí Ẹja tó wà lódò?
Ẹni tó sọ Eku sómi,
Ló fẹ́ ríkú Eku,
Ẹni tó mẸ́ja lódò sókè eèpẹ̀ ńkọ́?
Onítọ̀hún fẹ́ rẹ́yìn ọmọ Ẹja ni.

Ẹni tó fẹ́ mẹ́yẹ nígbó tó ń dána sungbó,
Ìyẹ́ nirúu wọn ń wò lẹ́yìn ẹyẹ,
Ẹni tó bá mẸjá lómi
Ló wu kíṣà níkà.
Inú ibú nílé Ẹja
Ẹja lò-gbódò-yan-fanda lómi

Oníríuurú Ẹja ló ń bẹ lómi:
Koté ń bẹ, Sáwá ń bẹ,
Ìgannìkú ń bẹ, Tìlápíà ń bẹ
Aláràn-án wa lódo,
Ẹja wẹ́wẹ́ tó wà lódò ńkọ́?
Ẹja níńlá kò gbẹ́yìn lódò
Ẹja tó tóbi bí Erinmi.
Àrọ̀gìdìgbà ń bẹ lomi,
Ẹni tó rẸ̀ku lódò ló réèmọ̀.

BẸ́ja ṣe bómi rẹ́ tó,
Omi ló tún ń ṣekú pẸja.
Bí wọ́n bá lómi ló máa ṣe Ẹja jinná
Ẹ má rò pérọ̀ ni
Ètò Ọba Aṣẹ̀dá ni,
Ẹja ló lomi, omi ló lẸja
Èto àyànmọ́ ni kì í ṣòògùn. (Àtinudá Fálẹ́yẹ, 2024)

Ẹran omi ni Ẹja gẹ́gẹ́ bí àbùdá ti Olódùmarè fi ṣẹ̀kẹ́ẹ̀ rẹ̀. Abájọ tí Akéwì fi tọ́ka sí àtẹnumọ́ èrò náà ní Ìlà (1) kìn-ín-ní, (14) kẹrìnlá, (20) ogún, àti (23) ìlà kẹtàlélógún, pé inú ibú ni a ti lè rí Ẹja. Àkíyèsí ìwà ìkà ẹ̀dá nípa sísọ Ẹja di ìjẹ fún ọmọ ènìyàn ni ó lè mú Ẹja lọ sókè eèpẹ̀. Èyí ni Akéwì ṣe sọ pé:

…Ẹni tó bá mẸjá lómi
Onítọ̀hún fẹ́ rẹ́yìn ọmọ Ẹja ni. 24.

…Ẹni tó bá mẸjá lómi
Ló wu kíṣà níkà.
Inú ibú nílé Ẹja
Ẹja lò-gbódò-yan-fanda lómi.

**7.3.2 Kọ̀ǹkọ̀:** Ní ti Kọ̀ǹkọ̀, ó jẹ́ ìran ẹran agbó-mi-ṣọlá nínú ẹranko ti ó ń bá ènìyàn gbé àyíká. Títọ-títọ ni wọ́n fi yàtọ̀ sí Ẹja tí ó ń gbé inú omi. Ẹja máa ń jẹ ara wọn, ṣùgbọ́n Kọ̀ǹkọ̀ àti Àkèré kì í ṣe bẹ́ẹ̀. Kọ̀ǹkọ̀ ní ìjọra pẹ̀lú Àkèré, àti ọ̀pọ̀lọ́, bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé ìyàtọ̀ tún wà. Àwọn ènìyàn kì í jẹ ọ̀pọ̀lọ́ fún àwọn ìdí kan, àmọ́ ẹran jíjẹ ni Kọ̀ǹkọ̀ àti Àkèré. Oríkì **Kọ̀ǹkọ̀:**

**Kọ̀ǹkọ̀**
Ọ̀tọ̀ lọ̀pọ̀lọ́, ọ̀tọ̀ ni Kọ̀ǹkọ̀
Bẹ́ẹ̀ sì ni Ọ̀tọ̀ lÀkèré.
Àkèré ṣe é je, Kọ̀ǹkọ̀ sì ṣe é jẹ
Ọ̀pọ̀lọ́ abara yíyi,
Ẹni jỌ̀pọ̀lọ́ bíkú bá ń bọ̀ kó mọ́ tìlèkùn.
Títọ-títọ niwọ́n fi jọ ra wọn
Ọ̀san gangan wọ́n á pirọrọ;
Bálẹ́ ò bá lẹ́, wọn kì í ké.
Bó bá dalẹ́, kíkée wọ́n a máa pọ̀,
Àtàkèré àti Kọ̀ǹkọ̀ àwọn ni wọ́n lorin.
Wọ́n dára lóunjẹ
Wọ́n tún dùn létè. (Àtinudá Fálẹ́yẹ, 2024)




Gẹ́gẹ́ bí akéwì ti sọ, ìhùwàsí tiwọn ní kí wọ́n máa dákẹ́ bí ẹni tí kò ní agbára kankan ní ojú ọ̀sán. Àmọ́ bí ó bá di alẹ́, gbogbo ẹ̀dá tí wọ́n bá múlé tì ni wọ́n máa ń kọrin fún, láìgbowó

iṣẹ́. Tí wọn yóò sì máa da àlàáfíà etí ẹ̀dá láàmú ní ọ̀pọ̀ ìgbà, ti omi bá dùn wọ́n lára. Ìfẹsẹ̀ múlẹ̀ èrò wa jade láti ẹnu ìpèdè Akéwì, nígbà tí ó sọ pé:

…Ọ̀san gangan wọ́n á pirọrọ
Bálẹ́ ò bá lẹ́, wọn kì í ké.
Bó bá dalẹ́, kíkée wọ́n a máa pọ̀,
Àtàkèré àti Kọ̀ǹkọ̀ àwọn niwọ́n lorin.

Àwọn ènìyàn máa ń fi Àkèré àti Kọ̀ǹkọ̀ ṣe ìjẹ àdídùn lórí oúnjẹ wọn. E gbọ́ ti Akéwì ní:

Wọ́n dára lóunjẹ
Wọ́n tún dùn létè.

**7.3.3 Ọ̀nì:** jẹ́ ẹran(ko) tí ó lè jẹ nínú omi, àti lókè omi (lórí ilẹ̀). Èyí ni Akéwì ṣe fún un ní orúkọ oríkì yìí:

Jomijòkè lỌ̀nì nínú ẹran, 6.
Àtòkè àtilẹ̀ kò síbi tỌ́nì kì í gbé. 7.

Agbára ìṣẹ̀dá tí Olódùmarè fún ẹran(ko) yìí ni ó fi lè ṣe gbogbo ìhùwàsí àti àbùdá àkóónú oríkì tí Apohùn hun jọ fún un:

**Ọ̀nì:**
Jíjọ láṣán ni wọ́n jọra wọn
Awọ́nríwọn yàtọ̀ Ságílíńtí
Ọ̀nì le jọ Aláǹgbá
Dídúró wọn, wọ́n sì tùn lè jọra
Ọ̀nì lọ̀gá ẹran bá a bá pín wọn sílẹ̀ nípò.
Jomijòkè lỌ̀nì nínú ẹran,
Àtòkè àtilẹ̀ kò síbi tỌ́nì kì í gbé.
Bó ṣe ń dọdẹ inú omi
Ló ń dọdẹ ilẹ̀ káàkiri.
Ọ̀nì ló nípọn-láyà bí-ì-rá
Ẹran Ọ̀ní yi lẹ́nu, ó dùn níkùn.
Iná lójú, eyín lẹ́nu
Jomijòkè tó ǹ fàyà fà.
Kò séni tỌ́nì ò le fìjà pàdé,
Bó ṣè ènìyàn, bó sì ṣẹranko.
Ọ̀nì lẹran abikú-lórí-èékánná,
Ikú lórí eyín, ikú lórí lẹ́nu.
Ọ̀ní tóbi.
Ó níyì lódò. (Àtinúdá Fálẹ́yẹ, 2024)




Lára agbára àṣẹ tí àwọn ìsọ̀rí ìpín àkọ́kọ́ ní lórí ìṣẹ̀dá ẹranko yòókù, gẹ́gẹ́ bí Olódùmarè ti fún ẹ̀dá ènìyàn ni ó fa ìsọdọhúnjẹ tí ìsọ̀rí náà fi àwọn ìsọ̀rí yòókù ṣe. Àkíyèsi ni pé, Ọ̀nì jẹ́ ẹran dídùn lẹ́nu ènìyàn:

Ẹran Ọ̀ní yi lẹ́nu, ó dùn níkùn. 11.

Bákan náà ni Ọ̀nì ní àgbára láti gba ara rè sílẹ̀ lọ́wọ́ ewu, yálà lórí ilẹ̀ tàbí nínú omi. Èyí jẹ́ ara àbùdá aṣèyàtọ̀ tí ẹran(ko) náà ní, tí ó tún mú un yàtọ̀ sí ìṣẹ̀dá ẹran(ko) yòókù bí

ẹja, kọ̀nkọ̀, àkèré tàbí àwọn ẹranko tí ènìyàn kì í sìn. Abájọ tí Akéwì fi kìlọ̀ nípa àbímọ́ ìwà ẹranko náà pẹ̀lú ìpèdè inú oríkì Ọ̀ní ní ìlà (14 sí 18) ìlà kẹrìnlá sí ìlà kejìdínlógún:

Kò ṣéni tỌ́nì ò le fìjà pàdé
Bó ṣè ènìyàn, bó sì ṣẹranko.
Ọ̀nì lẹran abikú-lórí-èékánná,
Ikú lórí eyín, ikú lórí lẹ́nu.
Ọ̀ní tóbi.
Ó níyì lódò.

## 7.4 Ìsọ̀rí Abẹ̀mí Ẹyẹ: Abìfò-Lójú Ọ̀run

**Ìsọ̀rí ọ̀wọ́ kẹrin**: ni ìṣẹ̀dá abẹ̀mí tí wọn ń lò sí ọ̀jú ọ̀run, tàbí inú òfuurufú ju ìbòmíràn lọ. Kò sí àkókò tí wọn kò ní ànfàànì láti fò, yàtọ̀ sí ìgbà tí atẹ́gùn líle bá ń fẹ́ tàbí nígbà tí òjò bá ń rọ̀. Bákan náà, a lè pè ìṣẹ̀dá abẹ̀mí yìí ní ìṣẹ̀dá abìfò-lójú-ọ̀run. A gbọ́dọ̀ yán án pé, àwọn ìsọ̀rí abẹ̀mí wọ̀nyìí náà lè gbé orí ilẹ̀ láti jànfàànì ohun mìíràn tí ó ń gbé orí ilẹ̀, ṣùgbọ́n nítorí àbùdá wọn, òkè lójú ọ̀run ni ààyè ìfò wọn pọ̀ sí jù, bí wọ́n bá fẹ́ rìn, tàbí tí wọ́n bá fẹ́ yan. Ìdí ni pé, wọ́n ní ìyẹ́ lápá wọn. A tilẹ̀ lè pè wọ́n ní ẹyẹ abìyẹ́. Àpẹẹrẹ wọn ni: Igún, Ọ̀kín, Àṣá, Àwòdì, Kannakánná, Ẹyẹ "Ìyà mi" àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.

Lára àyípadà tí a ṣàkíyèsí ni pé, látijọ́, inú igbó, tàbí ìjù réré ni Ọ̀kín máa ń gbé. Àmọ́ lóde-òní, àwọn ìṣẹ̀dá ènìyàn bí i ọba, ọlọ́rọ̀ àti àwọn ọ̀tọ̀kùlú ìlú ti ń sin ẹyẹ tí a ń pè ní Ọ̀kín yìí. Ẹ jẹ́ kí a wo oríkì rẹ̀.

### 7.4.1 Ọ̀kín

Ọ̀kín, ọlọ́jà ẹyẹ.
À-rí-mà-leè-lọ, à-wò-padà-sẹ́yìn,
Ọba ẹyẹ tíí fadé orí sọlá,
Ọ̀kín aláràn an ẹyẹ.
Ọba ẹyẹ a-jí-fọlá-bora-bí-aṣọ;
Ọmọ̀-nà-ko-yẹ̀rì
Ẹyẹ a-jí-fàrán ṣète.
Ìmọ̀kín aládé,
Ara Ìlọ́jà,
A-sú-dẹdẹ-bí aró
Ìràwọ̀-sú-dúdú gbayì.
Òṣùpá ò pé méjì
Gbójú Ọlọ́run wò réré;
Ẹyẹ bí Ọ̀kín kò sí láàrin ẹyẹ.
Ẹyẹ a-jí-ginni, a-rìn-ginni,
A-fìrìn-pẹ̀lẹ́-ṣe ara è-lọ́jọ̀.
Òkú Ọ̀kín, owó ni,
Ààyè Ọ̀kín, owó ni.
Ọba tó jẹ tó ní tỌ̀kín ò sí
Kó má fi ìyẹ́ Ọ̀kín ṣádé orí
Bó bá fìyẹ́ ṣádé lórí,
Ó jalè Ìmọ̀kín, ará Ìlọ́jà ni.
Òṣùpá tinú òòkùn là wáyé;
Ìmọ̀kín, ará Ìlọ́jà,
Afínjú ẹyẹ tí í fọlá rera. (Àrẹ̀mú, 1979)



Akéwì jẹ́ kí a rí òye ẹwà lára ẹyẹ náà nípasẹ̀ oríkì tí ó hùn jọ fún un. Ìlà (1) kìn-ín-ní sí ìlà (7) keje ló tọ́ka sí ọ̀rọ̀ ẹwà ẹyẹ yìí. Àbùdá ẹwà tí Olódùmarè fún ẹyẹ yìí kò wọ́pọ̀ láàrin àwọn ẹyẹ yòókù. Abájọ tí Akéwì fi sọ pé:

À-rí-mà-leè-lọ, à-wò-padà-sẹ́yìn,
Ọba ẹyẹ tí í fadé orí ṣọlá,
Ọ̀kín aláràn-an ẹyẹ.
Ọba ẹyẹ a-jí-fọlá-bora-bí-aṣọ…

Àkíyèsí wa ni pé ọ̀pọ̀ àwọn ọba ni wọn n sin eye yìí lóde-òní. Bí a bá sì wo bí ẹyẹ náa ṣe máa n rìn bí ó bá wà lórí ilẹ̀, ó dájú pé eni tí kò ní ìrírí rè rí, bí ó bá ti ka oríkì tí akéwì fún ẹyẹ náà pẹ̀lú àpèjúwe rẹ̀, bí ó bá padà rí ẹyẹ náà, kò lè sí àṣì-mú rárá:

Ẹyẹ a-jí-ginni, a-rìn-ginni,
A-fìrìn-pẹ̀lẹ́-ṣe-ara-rè-lọ́jọ̀.

Àkíyèsí ni pé, gbogbo ara ni Ọ̀kin gẹ́gẹ́ bí ẹyẹ fi wu akéwì tí ó ṣẹ̀dá oríkì fún ẹyẹ náà. Tí ó fi jẹ́ pé, apohùn kò rí ibùdó kankan lára ẹyẹ náà tí ó ní àbùkù, tàbí ìwà àlèébù ìbínú lára ẹwà ẹyẹ náà.

**7.4.2 Ẹyẹ Igún**: jẹ́ ẹyẹ tí àwọn ènìyàn kì í sìn, inú igbó ni òun náà máa ń gbé jìnnà sí ènìyàn. Ẹyẹ abìfò ni. Ọ̀kan lára àwọn ẹyẹ tí ìgbàgbọ́ ìran Yorùbá fi hàn pé àwọn "Ìyà mi" máa n ṣàmúlò láti rán níṣẹ́ ni ẹyẹ igún. Yorùbá tilẹ̀ gbà pé a kì í jẹ igún, a kì í sì fi bọ Orí, bí a ti máa ń ṣe àmúlò ẹyẹlé tàbí adìyẹ. ọ̀wọ̀ àti ẹ̀rù wà lára ẹyẹ náà. Ẹ jẹ́ kí a wo oríkì rẹ̀.

**Igún**
Igún, ọmọ ajẹbọ,
Lábàlúyẹ̀gẹ̀, ọmọ a-jẹ̀-gbin-kásì-má-bì;
Igúnnugún tiiri ẹnu gọ̀gọ̀
Abàlúyẹ̀gẹ̀, Igún kò nírun lórí
Igún nírun lórí,
Ebọ ló mórí Igún lo
Tó fi pá kánrin-kéṣe.



Ká rúbọ àgùntàn, ká tún mádìẹ ọ̀sọ́rọ́,
Ká fi rúbọ sórita
Gbogbo a-jí-mú-tẹbọ gbọ́
tIgún ni wọ́n ń ṣe.
Igúnnugún tí í jẹun ẹbọ gbe.

Òjò gbogbo lórí akítì ní í dá lé.
Aró pẹ́ lómi, ó dòkùsù,
Lábàlúyẹ̀gẹ̀ pẹ́ lẹbọ, ó dalákìsá àṣọ.
Ìṣẹ́ ńṣe Gún, Àwòdì ò bá Gún rà.
Ojú ń pọ́n Gún, ẹyẹ-oko ò bá Gún ṣe.
Igún torí ẹbọ, ó foríta ṣe lé,
Lábàlúyẹ̀gẹ̀ torí ẹ̀gbin, ó fàkìtàn ṣè yẹ̀wù.
Igún lẹ́bọ jíjẹ ò ṣe nǹkan,
Kó yíni lára nìkan lèèwọ̀.
Afínjú ẹyẹ tí í fàkísà ṣe rọ̀rí. (Àrẹ̀mú 1979: 26)

Fún àpẹẹrẹ, nínú oríkì tí a fà yọ nínú èrò Àrẹ̀mú (1979) lókè yìí, ó ti fi ìṣe àti ìhùwàsí ẹyẹ igún hàn nínú oríkì tí ó ṣẹ̀dáà yìí. Pẹ̀lú èrò ìjìnlẹ̀ pé àwọn "Ìyà mi" máa ń gba ẹ̀bẹ̀,

ẹbọ, àti ìpèsè ẹ̀dá ènìyàn ní oríta, gẹ́gẹ́ bí a ti rí i nínú oríkì tiwọn (Fálẹ́yẹ, 2024) pé, "àwọn lonímọ̀-oríta ní gbogbo òru", tí a sì tún ní òye pé ẹyẹ igún jẹ́ ọ̀kan nínú ẹyẹ tí àwọn àgbà lè rán níṣẹ́, kò sí ẹ̀rí mìíràn tí ẹ̀dá ń wá kiri láti gbà pé ìbáṣepọ̀ wà láàrin àwọn ènìyàn abẹ̀mí àti ẹyẹ abìfò, bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé eranko igbó tí kì í bá ènìyàn gbé ilé ni.

Ohun tí a ń sọ ni pé ẹ̀rí agbára ìṣẹ̀dá tí àwọn akéwí ní láti hun ìrírí papọ̀-sọ-di orúkọ tàbí oríkì fún nnkan àyíká jẹ́ èròjà pàtàkì. Ìmọ̀ nlá ni eni tí ó bá ní ànfààní láti ka oríkì náà, tàbí tí ó gbọ́ ọ, tí ó sì fi ṣe àwòtà ìmọ̀ fún ẹ̀kọ́ láti inú ìlò oríkì tí àwọn alátinúdá náà ń ṣẹ̀dá. Bákan náà ni a rí ìhùwàsí àgbọ̀n, èku àti àwọn ẹ̀dá ajẹmẹ́ranko abáni-gbé-àyíká mìíràn nínú oríkì wọn.

## 8.0 Ìṣàfihàn Ojúṣe nínú Oríkì

Ní ọ̀nà mìíràn, gbogbo ìsọ̀rí ẹ̀dá tí a pè ní takọ-tàbo lábẹ́ ìpínsísọ̀rí mẹ́rẹ̀ẹ̀rin yìí ni Yorùbá gbà pé wọ́n ní ojúṣe láwùjọ yòówù tí wọ́n bá wà, bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé, àwùjọ kọ̀ọ̀kan máa ń ra ojúṣe bọ ìṣẹ̀dá lọ́rùn. Ọ̀rọ̀ ojúṣe yìí náà ló bí èrò àti ìgbàgbọ́ pé Olódùmarè tí ó dá ẹni kọ̀ọ̀kan sí àwùjọ tí ó ba ara rẹ̀, ti dá ojúṣe fún ún. Nítorí naà, bí a bá ń sọ̀rọ̀ nípa ojúṣe, a ń retí pé ìṣẹ̀dáà kọ̀ọ̀kan gbọdọ̀ mọ ààlà ojúṣe rẹ̀ sí ti ìṣẹ̀dá ọmọnìyàn, tàbí tí ìṣẹ̀dá abẹ̀mí ajẹmẹ́ranko. Ojúṣe sí ara ẹni, ojúṣe sí ènìyàn, àti ojúṣe sí ìsọ̀rí ẹ̀dá mìíràn tí wọ́n ń bá ènìyàn jọ gbé àwùjọ pàpọ̀ kò gbẹ́yìn nínú ìhùwàsí àti ìṣe ìran Yorùbá. Ìdí nìyí tí ó fi jẹ́ pé, bí ìṣẹ̀dá ọmọnìyàn kan bá ń ṣe àmúsìn ìṣẹ̀dá ajẹmẹ́ranko gan an, wọ́n tún máa ń gbà á bí iṣẹ̀ láti rí i pé, wọ́n tọ́jú àwọn ọ̀sìn náà bí ó ti yẹ. Yàtọ̀ sí pé ìṣẹ̀dá ajẹmẹ́ranko jẹ́ ohun ọ̀sìn, ohun tí wọ́n lè jẹ, ohun tí wọ́n lè fi ṣe ètùtù ìràpadà ẹ̀mí, tàbí tí ó lè jẹ́ orísun ìpawó wọlé fún ìṣẹ̀dáà ènìyàn. Àwọn ìṣẹ̀dáà ènìyàn máa ń fi ìhùwàsí wọn hàn sí ìṣẹ̀dá ajẹmẹ́ranko (tí kò lè panilára), gẹ́gẹ́ bí i ohun tí wọ́n ní ìbọ̀wọ̀fún fún, nípa ṣíṣe ojúṣe rere sí wọn. Àpẹẹrẹ bẹ́ẹ̀ ní a rí lára Ajá, tí ó lè fi ojú olè hàn, ó sì lè ṣààbò lórí ẹni tí ó n sìn ín àti ilé rẹ̀. Bákan náà ni ìwúlò Olóńgbò tí a ń sìn nínú ilé, àti ìlànà ìdẹ́kun eku tí ó n yọni lẹ́nu nínú ilé, tàbí ní àyíká. ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn eranko náà ni wọ́n wúlò fún ànfààní ìje, àti ọ̀nà ọlà fún ẹ̀dá ènìyàn nípa pé ènìyàn n sìn wọ́n.

## 9.0 Ìṣàfihàn Agbára Ìṣẹ̀dá Apohùn nínú Ìlò Oríkì

Gẹ́gẹ́ bí ẹ̀rí ìwádìí tí a ṣe, tí àkọsílẹ̀ awọn onímọ̀ ìṣaájú (Bíòbákú, 1973), Akínyẹmí (1993 & 2000), Ládélé (2008), Fálẹ́yẹ (2011 & 2024), àti àwọn mìíràn fi hàn ni pé, abala kan gbòógì tí kò ṣe é fi ọwọ́ rọ́ sẹ́yìn nínú àṣà àti ìṣe Yorùbá ni ìṣàmúlò oríkì. Oríkì jẹ́ irúfẹ́ ẹ̀yà ohun ẹnu ìran Yorùbá kan, tí àwọn apohùn tàbí akéwì máa fi ń ti èrò ìjìnlẹ̀ wọn jádé. Oríkì lè ṣíṣé àká èrò, níbi tí àwọn apohùn fi èrò ìjìnlẹ̀ pamọ́ sí, tí wọ́n kàn ń sí i fún ẹni tí ó bá ń wá ìmọ̀ ni. Bákan náà, láti fi ipò pàtàkì tí ohun tí àwọn akéwì bá ń ki ìpọ̀nrí rẹ̀ wà hàn, wọ́n máa ń fi oríkì ṣe ọ̀ṣọ́, tàbí ìyìn fúnni. Àgbékalẹ̀ oríkì jẹ́ ohun tí a lè fi gbádùn ara ẹni, tàbí láti fi kọ́ àwọn olùtétísí lẹ́kọ̀ọ́ nípa ohun kan pàtàkì. A sì lè kọ oríkì sílẹ̀, nígbà tí ìmọ̀ mọ̀-ọ́n-kọ mọ̀-ọ́n-kà ti wọ àwùjọ Yorùbá.

Akéwì lè ṣẹ̀dáà oríkì fun ìṣẹ̀dá abẹ̀mí tàbí aláìlẹ́mìí kan, kí ó kọ ọ́ sínú ìwé gẹ́gẹ́ bí i àwọn ìwé ewì *oríṣìíríṣìí* (Olábímtán, 1978), ìwé *àròfọ̀ Àfàìmọ̀* (Ìṣọ̀lá, 1984), àti ìwé ewì *Àròfọ̀ ọmọ Sàbì* (ọmóléwu, 2023), tàbí ìwé àkójọ *oríkì orílẹ̀* (Adébóyè, 2020) tí àwọn ònkọ̀wé wọ̀nyìí kọ. Bákan náà ni akéwì tàbí apohùn lè ṣẹ̀dáà oríkì, kí ó ká a sínú fọ́nrán gẹ́gẹ́ bí i apẹ̀sà Àṣàbí ọ̀jẹ̀ (2016 & 2024), Ayílárá-Ajóbíewé (2016, 2010 & 2023), àti bí a ti rí àpẹẹrẹ nínú iṣẹ́ apohùn Fálẹ́yẹ (2009, 2010, 2016 & 2017) nínú àkásílẹ̀ fọ́nrán tí àwọn ènìyàn àwùjọ ní ànfààní láti padà tẹ́tí sí, ní ààyè, àti àkókò tí ó bá wù òlùgbọ́ pẹ̀lú ìmọ̀ ẹ̀rọ ìgbàlódé. Ní pàtàkì, oríkì lè dá lé ènìyàn abẹ̀mí, ó sì lè dá lé èrò àròjinlẹ̀ nípa ẹ̀rànko, tàbí ohun tí ó ṣe pàtàkì sí ẹni tí ó hun oríkì náà jọ nípa àwùjọ tàbí àyíká rẹ̀.

Ìgbágbọ́ Yorùbá ni pé "Olúdá ayé àti ọ̀run ni Olódùmarè. Ìran Yorùbá sì gbàgbọ́ pé Olódùmarè yìí kan náà ni Aṣẹ̀dá tí ó ní ìmọ̀ láti dá gbogbo ohun tí ó wà ní àwùjọ asùwàdà tí a bá, ti ohun náà ń mí, tí ó sì ń ṣe bí i ènìyàn, tàbí ohun tí a pè ní abẹ̀mí ajẹmẹ́ranko. Abájọ tí gbajúgbajà akéwì ọ̀kọrin Yorùbá kan fi sọ pé:

Ẹ jẹ́ kí n fi orín mi yin Olúdá ayé, Olùdá ọ̀run
Mọrí-mọrí ayé, ọba tó mọrí gbogbo ẹ̀dá ènìyàn.

Ìpèdè "Olúdá ayé, Olùdá ọ̀run" náà ń tọ́ka sí gbogbo agbára, àti òye ìkápá tí Olódùmarè ní lórí ohun gbogbo láyé àti lọ́run, gẹ́gẹ́ bí èrò ìjìnlẹ̀ tí gbajúgbajà akéwì ọ̀kọrin Yorùbá náà ni. Bákan náà ni akéwì yìí ń fi agbára ìṣàmúlò èdè rẹ̀ nínú ìlò òríkì, àti ìgbàgbọ́ rẹ̀ nípa ìṣẹ̀dá Olódùmarè hàn ni. Ìlà (2) kejì nínú àyọlò òkè náà ń tọ́ka sí ìkápá Olódùmarè lórí gbogbo ohun tí a bá lè pè ní ẹ̀dá tàbí ìṣẹ̀mìí - èyí ní jíjẹ́ nnkan kan, gẹ́gẹ́ bí i alàáyè tí ó sì ń mí.

**9.1 Ìṣàfihàn Ìṣẹ̀dá Abẹ̀mí Ajẹ́mọ́yanu ọwọ́ Olódùmarè**

Lára àwọn ìṣẹ̀dá ọwọ́ Olódùmarè tí àwọn Yorùbá máa ń kà sí ohun ìyanu ni àwọn ìṣẹ̀dàá tàbí ohunkóhun tí a pè ní abẹ̀mí ajẹ́mẹ́ranko tí wọn ń gbé àyíká àwọn ènìyàn. Nítorí pé ìran Yorùbá máa ń ṣe àfihan àwọn agbára Olódùmarè lórí ohun tí ó dá sí àwùjọ ayé, nínú ìlo oríkì àwọn apohùn náà, a máa ń rí àfihàn ìyàlẹ́nu wọ̀nyìí. Bákan náà ni àwọn akéwì tàbí apohùn máa ń ṣe àfihàn ìyanu àti ìyàlẹ́nu lórí àwọn nnkan ìṣẹ̀dá mìíràn tí Olódùmarè dá, tí ó yàtọ̀ sí ìsọ̀rí ènìyàn, yàlà nípa àfijọ ìṣe ènìyàn, tàbí ìṣe ìyàtọ̀ tí ó múni tún inú rò, nípa àyíká ẹ̀dá. ọ̀rọ̀ tàbí ìṣẹ̀lẹ̀ ìyanu náà lè jẹ́ bí nnkan ìṣẹ̀dáá náà ṣe tóbi tó, tàbí bí ó ṣe kéré tó, ṣùgbọ́n tí ìṣe abẹ̀mí náà mú ìyàlẹ́nu dáni tàbí nípa ìlò agbára ìṣẹ̀dá rẹ̀.

Agbára tí Olóngbò ní lórí Eku ni ó ṣe lè ràjò, tí ó dé, ti gbogbo omo Eku wá sùn nínú àgbàrá ẹ̀jẹ̀. Akéwì ní:

…Níjọ́ tọ́kọ Eku dé
Gbogbo Eku ilé ló sùn nínú ẹ̀jẹ̀.
Ológìnní, a réèkán-ná dádé.

Ìpèdè "Ológìnní, a réèkán-ná dádé" n tọ́ka sí agbára ìlò àwọn nnkan àṣe ara rè tí ó fi lè ṣe ikú pa abẹ̀mí tí ó kéré níye sí ìṣẹ̀dá tirẹ̀ ni.

Bí a bá wo Ẹ̀fọn fún àpẹẹrẹ, nínú oríkì tí a gbà jọ, a ó rí i pé ẹ̀dá abẹ̀mí tí ó kéré ni, ṣùgbón ọṣẹ́ tí ó lè ṣe fún ẹ̀dá ènìyàn kò kéré. Akéwì ní:

Bíntín lẹ̀fọn,
Ẹ̀fọn le múni gbára ẹni létí.
Takọtabo lÓluwa Ọba dáyé,
Takọtabo lOlúwa Ọ̀ba dá wọn fún wa.
Akọ Ẹ̀fọn ń bẹ níbẹ̀ tí ò le,
Abo Ẹ̀fọn burújài wọ́n ń ṣèkà!
Akọ Ẹ̀fọn wọn kì í jẹ ni,
Àmọ́ kíké wọn
Kò ní i jéèyàn ó sùn bó bá fẹ́
Ó le mú takọtabo wọ̀yáàjà

Ìlà (3) keta sí (7) ìlà keje ń ṣe ẹ̀rí pé tako-tabo ni ìṣẹ̀dá ẹranko náà tí ó sì ní àbùdá àtilè-bí bí ènìyàn lábẹ́ ìsọ̀rí ìpín àkókó tí a ṣe. Èwu ìpalára fún ẹ̀dá ènìyàn tí kò bá lákàsí tí ìṣẹ̀dá Ẹ̀fọn lè ṣe fúnni ni ìlò oríkì tí akéwì hun jọ fún un.

Atá kéré ọkọ ojú lata ń ṣe;
Ẹ̀fọn lè kéré, iṣẹ́ ọwọ́ Ẹ̀fọn ò kéré.

Ìlà kefà tilẹ̀ sọ ó bí ìyànu, àti orúkọ fún Ẹ̀fọn ni pé: "Abo Ẹ̀fọn burújài wọ́n ń ṣèkà". A jẹ́ pé ìkà-ẹ̀dá ní í ṣe, bí wọ́n ti rí bíntín ti ìlà oríkì (1) kìn-ín-ní sọ nípa rẹ̀. Eku náà tún jẹ́

ìsòrí ẹ̀dá tí ó kéré lótòótọ́, ṣùgbọ́n ìbàjẹ́ tí ó lè dá sínú ayé láwùjọ ẹ̀dá ènìyàn kò kéré. Abájọ tí Akéwì fi ṣàfihàn èrò yìí ní ìlà kọkàndínlógún (19) sí ìlà ọgbọ̀n (30).

Ìwà ìkà ń bẹ lọ́wọ́ eku ilé gbogbo.
Wọ́n ń jaṣọ, wọ́n sì le bàwé jẹ́.
Ekú ti jẹ ìwé ẹ̀rí Alákòwé rí
TÁlákòwé sì dalákorí lọ́wọ́ ọsẹ́ téku ṣe!
Eku tí í túlé lọ́kọláya
Tó jẹ̀wé ẹ̀rí ìgbeyàwó,
Táya dalákọra alàìkíyèsí lọ́wọ́ ìjọba
Lákòókò àyẹ̀wò ìwé ẹ̀rí fún iṣẹ́!
Eku ni jélé-jele
Eku ni jewéjẹ̀wé tí kò ránni-níṣẹ̀
Eku ò lóhun ò balú jẹ́.

Àkíyèsí wa ni pé, nígbà tí àwọn apohùn tàbí akéwì bá ń ṣe àgbékalẹ̀ àròjinlẹ̀ wọn, wọ́n máa ń fi àwọn èrò ìyanu bẹ́ẹ̀ pamọ́ sínú orin, èwì tí wọ́n ń ké, tàbí nínú oríkì tí wọn hun jọ, fún ìmọ̀ nípa ìṣẹ̀lẹ̀ tàbí ohun abẹ̀mí kan. Iṣẹ́ orin kan tí Àlàbí (2005) kọ fi èrò ìjìnlẹ̀ ajẹmóyanu yìí hàn nínú àtinúdá rẹ̀. Olórin náà ní "Mo rí ìyanu!", ìpèdè àmúlò rẹ̀ nìyìí kí ó tó máa ki Olódùmarè lọ pẹ̀lú àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ rẹrẹẹrẹ tí ó tọ́ka sí nínú orin rẹ̀. Ìgbà mìíràn, ó lè jẹ́ nípa ìhùwàsí ohun abẹ̀mí náà tí ó mú un yàtọ̀ sí àwọn ìsọ̀rí abẹ̀mí ẹgbẹ́ rẹ̀ yòókù, tàbí nípa ìhà tí akéwì náà kọ sí ohun abẹ̀mí, ní ìbámu pẹ̀lú ojú àmúwòye ènìyàn nípa ẹranko náà ni ó yà á lẹ́nu.  E wo ohun tí apohùn so nípa Ọ̀nì:

Ọ̀nì lọ̀gá ẹran bá a bá pín wọn sílẹ̀ nípò.
Jomijòkè lỌ̀nì nínú ẹran,
Àtòkè àtilẹ̀ kò síbi tỌ̀nì kì í gbé.

Agbára ìṣẹ̀dá ẹranko yìí tí ó fi yàtọ̀ ní ìrísí, ìṣesí, ìkápá àti àṣẹ ìṣẹ̀dá tí Olódùmarè fún un nìyẹn. Abájọ tí ìṣẹ̀dá ènìyàn méjì tàbí ẹranko méjì kò fi jẹ́ irú oríkì kan náà. Lára oríkì tí a fún Ọ̀nì ni: "Anípọn-láyà bí-ì-rá" ní ìlà kẹwàá (10) nítorí pé ẹranko náà kì í bẹ̀rù, kò sì sí ẹni tí kò lè dojú ìjà kọ; yàlà nínú omi tàbí nínú ilè gbẹrẹfun. Àbùdáà mìíràn tí ẹranko (inú omi) yìí ní ni pé:

Iná lójú, eyín lẹ́nu
Ọ̀nì lẹran abikú-lórí-èékánná,
Ikú lórí eyín, ikú lórí lẹ́nu.  (Àtinuda, 2024)

Akéwì fi Ọ̀nì wé ikú tí í pani. Nítorí pé kò sábà sí ibi tí ẹran-omi náà ti fi lè báni jà. Gbogbo ara, kìkì idà agúnnipa ni. Ìrísí àti ìṣesí rẹ̀ ló fa oríkì tí apohùn hun fún un.

### 9.2 Ìṣàfihàn Agbára àti Ìhùwàsí Àwọn "Ìyà mi / Àjẹ́"

Ìwádìí tí a ṣe fi hàn pé òkàn-lé-légbẹ̀ta (601) ni àwon ajogun ẹ̀dá tí ó wà láyé (https://en.wiktionary.org/wiki/Ajogun). Gbogbo àwọn ajogun náà ló sì ń gbógun ti ìran ọmọ ènìyàn. Ọ̀pẹ́fèyìtìmí (2010:14), Abímbọ́lá (1976) tile ṣàfihàn díè nígbà tí àwon onímò náà dárúkọ: Ikú, Àrùn, Ọ̀fò, Ẹ̀gbà, Ọ̀ràn, Ẹ̀wọn, Èpè, àti Èse, gégé bí i olórí àwọn Ajogun. Láìṣe iyè-méjì, àwárí àbọ̀ ìwádìí ìjìnlẹ̀ tí Ìlésanmí (2009:15) jábò rẹ̀ ti fi hàn pé àjẹ́ wà. Bákan náà ni ó gbà pé àwọn obìnrin ló awo Ajé jẹ mọ́. ọ̀pọ̀lọpọ̀ iṣẹ́ ìwádìí nípa àjẹ́ sì fi òye hàn pé àjẹ́ kì í ṣe òrò àwùjo ilè Yorùbá nìkan, bí kò ṣe pé jákè jádò gbogbo àgbáyé ni ìmò àjẹ́ ti hànde pé ó wà; àti pé awo obìnrin tí àwon ìran Yorùbá n dà pè ní Iyà mi náà ni àjẹ́.

Kódà, oríkì wọn fi wón hàn bí i arẹwà, tí Olódùmarè gbé agbára ìrísí takọ-tabo fún.

Ọ̀pìkí ẹlẹsẹ̀ osùn 87.

Bákan náà, agbára àtẹ̀gbé àti ìpàyà wà tí wọ́n lè dá boni:

Ọ̀tẹ̀lẹ̀kílẹ̀mì
Ọ̀tẹ̀lẹ̀kílẹ̀rọ́ gbàdàgbàdà
Omí nlá abojú nangun

Ìpèdè oríkì tí fà yọ nínú àkójọ oríkì òkè yìí fi hàn pé kò sí ohun tí wọ́n fé tẹ̀, tí Olódùmarè kò fún wọn tẹ̀. Abájọ tí wọ́n n jé - Ọ̀tẹ̀lẹ̀kílẹ̀mì, Ọ̀tẹ̀lẹ̀kílẹ̀rọ́ gbàdàgbàdà. Nínú ìse àwọn Ìyà mi ni oríkì yìí ti je yọ. Bí ó bá wù wọ́n, wọ́n lè fi ìrísí akọ hàn, tàbí tabo. Agbára àyídà-yídà tí Aṣèdàá ayé àti ọ̀run fún wọn ni.

Afínjú ẹyẹ
Ìyàmi Ọ̀dúndúnladé,
Obìnrin kúkurú rẹ́gírẹ́gí
Ìyà mi ẹléwù osùn
Ẹlẹ́wù ẹfun
Aláṣọ aró
Ẹyẹ ò-ṣorò-ṣe mọ̀gà-mọ̀gà.

Láti ìlà (1) kìn-ín-ní - Afínjú ẹyẹ - èwì yìí títí dé ìlà (7), keje a ó ṣàkíyèsí pé obìnrin tí ó lágbára àmúyẹ ẹwà ni àwọn "'Ìyà mi", pẹ̀lú àpèjúwe ẹ̀wà wọn gẹ́gẹ́ bí i afínjú ẹ̀dá. Bákan náà oríkì wọn ṣàfihàn èrò ìjìnlẹ̀ àti ìgbàgbọ́ tí ó tọ́ka sí wọn gẹ́gẹ́ bí alágbára tí wọ́n le gbé àwò ènìyàn tí ó rẹwà lọ́kùnrin, tábí lóbìnrin káni mọ́lé lójú oorun, àmọ́ tí ó jẹ́ pé jíjẹ ànfààní ẹwà àti ìbálòpọ̀ wọn lójú oorun lè bí ọ̀pọ̀lọpọ̀ ewù ìfàsẹ́yìn àti ìjákulẹ̀ fún ìwàláàyè ènìyàn. Ìlà kẹ̀rìnlá (14) sí Ìlà ogún (20) tọ́ka sí èrò ìjìnlẹ̀ yìí:

O-lànà màrin-màrin
Orí kíkún tíkò níná
Ọjà kíkún tí-kò-lérò
Olóbò A-kì-í-dó
Anídọ a-kì-í-fọwọ́-pà
Mìnì jọ̀jọ̀
Ìgbín onírun Àjẹ̀njẹ̀tán

**9.3 Ìkìlọ̀ pàtàkì** nípa àwọn "ìyà mi" ni oríkì wọn yìí ń tọ́ka sí fún ènìyàn tí ó bá ní iyè nínú pé- Olóbò A-kì-í-dó, Anídọ a-kì-í-fọwọ́-pà, ìwọ̀nyìí tún dà bí i èèwọ̀ pàtàkì tí akéwì yìí n sínni ní gbẹ́rẹ́ ìpàkọ́ fún nípa ìrísí ewà àwọn "Ìyà mi".

Olójòǹgbòdú obìnrin ikú,
Igúnnugún tí í bàlẹ́ a-jorí
Àkàlà balẹ̀ a-jẹ̀dọ̀
Ọlákàtá
Ọláràká
Ọlátàká ràgbàdà
Ìyà mi ọlọ́jà mẹ́rìndínlógún.

**9.4 Ìgbàgbọ́ àti Ìṣàfihàn Agbára Ààjìn (òru)**

Lára ìgbàgbọ́ ni pé, àwọn àjẹ́ máa ń ṣe ìpàdé ní òru, wọ́n sì ní agbára láti fò nínú ẹ̀mí lọ sí ibikíbi tí wọ́n bá fẹ́ lọ. Ìlà kẹjọ (8) sí ìlà kejìlá (12) oríkì ìsàlẹ̀ yìí tọ́ka sí ṣíṣe àmúlò agbàrà ọ̀gànjọ́, ààjìn tàbí àkókò òru tí ó yẹ kí gbogbo ọwọ́ ti pa, kí gbogbo esè ti pa pèlú.

Ẹyẹ mọ̀gàmọ̀gà sorò

Akéroro
Olóhùn roro
Olólá Ààjìn
Olókìkí òru…

Ara agbárà, àrà ọ̀tọ̀ tí àwọn apohùn máa ń fi hàn nínú oríkì àwọn àjẹ́ nìyìí. Igbàgbọ́ pé Olódùmarè tí ó gbé agbára ìkọ́lé-ayé lé àwọn Ajé lọ́wọ́, tí kò sì sí ẹni tí ó lè rí ìdí wọn, láìjẹ́ pé Aṣèdàá fún eni náà láàyè nìyẹn. ṣé Yorùbá bọ̀, wọn ní ẹrù ààjìn, kì í jẹ́ kálàìwo sán-nááni ara kiri. Bákan náà bí a bá wo ìlà (21) kọ́kanlélógún oríkì “Ìyà mi” yìí títí dé ìlà (37) kẹ̀tàdínlọ́gbọ̀n tí ó ń ṣe ìtọ́kasí ìrísí, ìṣesí, ìhùwàsí àti ìṣe wọn bí ìṣẹ̀dàá ẹranko (eye) tí wọn máa ń gbé àwo rè wò, láti rán níṣẹ́, a ó rí pé apohùn n jẹ́rìí sí ìse wọn ni.  Wọ́n lè ṣe bí ajá, ológìnní, tàbí ẹyẹ arẹwà tí wọn yóò sì máa dá gọ̀jọ-gọ̀jọ.

Akọ Ajá Aborí-gbóngbó
Ológìnní abìrìn-gìlọ̀gìlọ̀
Ẹyẹ abapá wíni
Ẹyẹ abẹsẹ̀ wíni
Ẹyẹ abìnrìn àrà lẹsẹ̀ méjèèjì
Òkìkí ọlá-afòru-làlú
A-ságaara, A-rìngaara
Àlùbọ́sà obìnrin
Gìirìgìirì dá
Ìdàndágìirì
Afẹnu gbobì-lọ́gànjọ́
Akáyínsoró
A-tobò-soró
A-fúyé-gẹngẹníyẹ̀ẹ́
Akọ ajá abòru-mẹ́rin
Akọ ajá abòru-mẹ́jọ
Abo ajá abòru-mẹ́rìndínlógún.

**9.5 Ìgbàgbọ́ nínú Agbára gbígba Èsè, Ètùtù tàbí** ẹ̀bẹ̀ ọmọnìyàn:Ohun tí Akéwì tí ó hun oríkì yìí ń tọ́ka sí, gẹ́gẹ́ bí ìgbàgbọ́ àwùjọ ìran Yorùbá ni pé, àwọn “Ìyà mi” náà ló lè gba ètùtù nípa ìfẹnu gbobì-lọ́gànjọ́.  Ìtọka sí ibùdó tí èrò ìjìnlẹ̀ náà fi hàn ni pé àwọn “àgbà” / Ìyà mi” ti lè gba ẹbọ ìsẹ̀dàá abẹ̀mí ni ìtọ́kasí: abòru-mẹ́rin… mẹ́jọ… àti mẹ́rìndínlógún tí apohùn n fi hàn.

Akọ ajá abòru-mẹ́rin
Akọ ajá abòru-mẹ́jọ
Abo ajá abòru-mẹ́rìndínlógún…

**9.6 Agbára láti Ìpani-láìmúdà lọ́wọ́:** Oríkì “Ìyà mi” fi hàn pé wọ́n ní agbára láti dá ṣẹ̀ríà fúnni. Nítorí agbara ìpani, tí kì í ṣe nítorí ogún ẹni tí wọ́n nífẹ̀ẹ́ sí. Ìlà (50) àádọ́ta sí ìlà (57) kẹ̀tàdínlọ́gọ́ta ni ẹ̀rí ìlò oríkì yìí.

Apani má hàgún
Ọ̀papara
Ọ̀kan hì, hì, hì
Afọ̀kánnáńmu
Atapájorí
Atìfunjẹ̀dọ̀
Ajẹ̀dọ̀ èèyàn ma bì
Adélé dolú

Akáyínṣoró 32.
A-tobò-soró 33.

Ẹwẹ̀, oríkì wọn tí ó tóka pé, kì í se ìgbà tí àwọn ìṣẹ̀dá Abẹ̀mí alágbára aboniyàn yìí bá mú idà ìjagun dáni nìkan ni wọ́n lè gbèjà ẹ̀dá hànde nínú oríkì wọn. Ìlà (89) kọkàndínláàádọ́rùn-ún sí ìlà (90) àádọ́rùn-ún fi ìhùwàsí wọn yìí hàn.

Apani-máyọdà 89.
Oníyẹ̀ẹ́ Abàmì. 90.

Ìlà (45) karùndínlọ́gọ́ta fi wọ́n hàn bí i agbeni-níjà. Nítorí pé kò sí ibi ti ojú wọn kò tó ìlà oríkì wọn jẹ́rìí sí agbára ìríran, àti olójú inú tí ó dá ohunkóhun tí ọ̀gbẹ̀rì ẹ̀dá tàbí awo mìíràn ìbá à fi sí oríta fún wọn.

Oníbàntẹ́ pèlènjà 45.
Anamọ-naye
Ọlọ́fun-Àásán
Oníkùn-èsè
Ìyà mi òsòròmọ̀nìgà

Òpìkí ẹlẹ́sẹ̀ osùn 87.
Olójú-ọ̀mọ̀ràn lóríta.

## 9.7 Ìgbàgbọ́ nínú Agbára Ìṣàmúlò Òríṣìíríṣìí Àwọ̀

Ìgbàgbọ́ ni pé oríṣìíríṣìí ni àwọ̀ tí àwon ẹyẹ àjẹ ń ṣe àmúlò. Àwọn wọ̀nyìí ni: dúdú, pupa, funfun àti àwọ̀ òféfèé:

Ìyà mi ẹléwù osùn,
Ẹlẹ́wù ẹfun, 5.
Aláṣọ aró…

Ìlà (4) kẹrin sí Ìlà (6) kefà ń tọ́ka sí onírúurú àwò tí àwọn "Ìyà mi" fẹ́ràn pẹ̀lú iṣẹ́ tí wọ́n fi ń jẹ́. Nínú ìlò oríkì yìí náà ni a ti rí òye èrò ìjìnlẹ̀ yìí.

## 9.8 Àfihàn Agbára Ìṣerere tàbí Síṣeni ní Sùtá

Ìgbágbọ́ àti àfihàn èrò tí àwon akéwì alárọ̀jinlẹ̀ apohùn tún máa ń hun mọ́ oríkì àwọn Àjẹ́ ni pé, Àjẹ́ ní ànfàànì agbára láti ṣe rere, kí wọ́n ranni lọ́wọ́ fún ìtẹ̀síwájú, ìdáàbòbò, àti jíjà fúnni:

Olómi tééré omi ayé
Olómi tààrà omi ilẹ̀
Onílé máwọ̀máwọ̀
Arógbà Aṣọ-má-balẹ̀
Ọ̀-ránni nísẹ́ fàyà tìí 80.
Alágogo lékúlékú

Ìpèdè tí a rí ní ìlà (80) ọgọ́rin fi hàn lóòótọ́ pé wọ́n ń ránni nísẹ́, "Ọ̀-ránni nísẹ́-fàyà-tí-ì", títí dé ìlà (81) ìkọkànlélọ́gọ́rin fi àwo Àjẹ́ hàn bí ìṣẹ̀dá tí ó n lé ikú jìnnà sí ẹni tí wọ́n bá fẹ́ dáàbò bò; bí ó bá jẹ́ Àjẹ́ ire ni ìṣẹ̀dá tí ẹlẹyẹ náà yàn. Bákan náà ni pé àjẹ́ lè ṣe ibi tí ó bá jẹ́ àjẹ́ ibi ni ìṣẹ̀dá agbára tí ó gbà. Bí a ṣe rí i pé àwọn "Ìyà mi" lè ṣe àmúlò Ewúrẹ́, Ajá, Adìyẹ, Olóngbò àti ọ̀pọ̀lọ́ jẹ́ ọ̀sìn tí ènìyàn ń lò nínú ilé, àwọn ẹranko (ilé) náà tún lè jẹ́ ààbò fún ènìyàn, tí wọ́n sì lè ṣíṣe ajé fún ẹ̀dá.

A ṣàkíyèsí pé ọ̀pọ̀ nínú àwọn abẹ̀mí inú omi bí Ọ̀nì, àti àwon eranko tí wọ́n ń bánigbélé, tí ẹ̀dà kò sìn tàarà náà ni wọ́n lè ṣe ẹ̀dá ní sùtá. A rí ìhùwàsí yìí lára Èfọn, Eku, Ọmọnílé àti oríkì Agbọ́n. (ẹ̀ ṣe àtúnwò oríkì tí a kó jọ).

### 9.9 Ìgbàgbọ́ àti Ìṣàfihàn Èrò Ìjìnlẹ̀ nípa Oúnjẹ àti Ìféràn Wọn:

Òmíràn nínú ìgbàgbọ́ àwùjọ ìran Yorùbá tí àwọn apohùn máa ń hun mọ́ oríkì àwọn àjẹ́ fi ìmúra wọn hàn (ìlà 41 sí ìlà 44), ìhùwàsí won nípa ìfẹ́ràn ìbàntẹ́ (ìlà 45), èsè (ìlà 48), ẹ̀jẹ̀, ẹ̀dọ̀ (ìlà 41), ìfun (ìlà 54 sí ìlà 56), àti àtọ̀ ọmọkùnrin. Ìgbágbọ́ àti èrò ìjìnlẹ̀ tí ó hànde nínú oríkì wọn nìyìí gẹ́gẹ́ bí i àwọn nǹkan tí wọ́n máa ń fi ṣe oúnjẹ wọn ní agbo èsè pípa nínú ìrúbọ awo Ifá.

Igúnnugún tí í bàlẹ́ a-jorí
Àkàlà balẹ̀ a-jẹ̀dọ̀
Ọlákàtá
Ọláràká
Ọlátàká ràgbàdà
Ìyà mi ọlọ́jà mẹ́rìndínlógún
Oníbàntẹ́ pèlènjà
Anamọ-naye
Ọlọ́fun-Àásán
Oníkùn-èsè
Ìyàmi òsòròmònìgà
Apani má hàgún ún
Ọ̀papara
Ọ̀kan hì, hì, hì
Afọ̀ókán-ná-mú
Atapájorí
Atìfunjẹ̀dọ̀
Ajẹ̀dọ̀ ènìyàn-ma-bì
Adélé dolú
Èrò dọ́nà dosù
Oníyẹ̀ẹ́ òwẹ̀erẹ̀
Àgọ̀ Àlàmosù
Ọlọ́yùn-bẹ́rẹ́ abìrùgbọọrọ
Ọláporó
Ọlákigbóó
Dángiri…

### 9.10 Agbára Àyípadà-rán-ni nísẹ́ (Rírán Ìṣẹ̀dá mìíràn nísẹ́):

Lára ìgbàgbọ́ ìran ìṣẹ̀dá ènìyàn tí àwọn alárọ̀jinlẹ̀ apohùn máa ń fi hàn nínú oríkì ni pé, àwọn àjẹ́ lágbára láti yíra padà sí irúfẹ́ ẹranko, tàbí ẹyẹ abìfò mìíràn tí ó bá wà ní ìkáwọ́ wọn. Ìyẹn ni pé, àwọn gẹ́gẹ́ bí ẹ̀dá ènìyàn lè paradà sí ẹrànko igbó (olóngbò igbó, ejò, ìgalà, Igún, ọ̀kín àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lo) tàbí kí wọ́n di ẹranko ilé bí i (ajá, olóngbò, ewúrẹ́, Adìyẹ, ọmọnílé, bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ) tàbí kí wọn di ẹ̀dá bí i ẹyẹ (Òwìwí, àkàlà, igún, kannakánná, àti àwọn ẹyẹ abàmì mìíràn). Ìgbágbọ́ ni pé wọ́n máa ń ṣe àmúlò ọmọ́nílé, tí wọ́n sì máa ń ran àwọn ẹranko wọ̀nyìí nísẹ́ nígbà yòówù tí wọ́n bá fẹ́. Bí a bá wo ìlà (68) kẹ̀jìdínláàádọ́rùn-ún títí dé ìlà (75) karùndínlọ́gọ́rin, nínú oríkì tí Fálẹ́yẹ (2024) ṣe àtòjọ, fi èrò yìí hànde nínú orúkọ tí apohùn fi kì wọ́n, láti júwe ìṣe, àti irú agbára tí wọ́n ní pẹ̀lú lílo onírúurú ẹyẹ:

Ìyà mi onígba ẹyẹ
Aláwòdì
O-lówìwí

Alápàńdẹ̀dẹ̀ ẹyẹ àgbàgbà.
Ìyà mi ẹlẹ́yẹ agbe
Olódídẹrẹ́ Ìwó
Ẹyẹ ò-sòrò-se-mọ̀gà- mògà
Ẹyẹ mọ̀gà mọ̀gà sorò… 75.

Bí a bá wòye dáadáa, ọ̀pọ̀ ẹyẹ tí àwọn Ìyà mi ń ṣàmúlò kì í se ẹyẹ tí ó n báni gbé ilé, bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé wọ́n máa ń rán àwọn ẹran ọ̀sìn àti kòkòrò abánigbélé, gbé àyíká mìíràn níṣẹ́. (Ogúndé, 1972 & Ilésanmí, 2009.) Bákan náà, bí a bá wo àbùdá oríkì tí a tò jọ fún ẹyẹ Igún, a ó ṣàkíyèsí pé àbùdàá àfijọ wà nínú oríkì àwọn Ìyà mi pẹ̀lú ẹyẹ yìí:

Igún, ọmọ ajẹbọ, 1.
Lábàlúyẹ̀gẹ̀, ọmọ a-jẹ̀-gbin-kásì-má-bì…

Ìlà méjì òkè yìí ń tọ́ka sí ọ̀rọ̀ ẹbọ tí a mo ẹyẹ Igún mọ̀ bí owó. Bákan náà ni ìlà kejì ń sọ̀rọ̀ nípa “jíjẹ ìgbín ìkàsìn láìbì” - Bí a ba wò oríkì yìí mọ́ ti Oríkì “Ìyà mi” tí ó sọ pé:

…a-jẹ̀dọ̀-ènìyàn má-bì…

Ó fẹ́rẹ̀ ní àfijọ. Èyí gan ni àròkò tí ó a gbà pé ìpèdè náà ń tọ́ka sí àjọṣepọ̀ láàrin àwọn Ìyà mi, àti ẹyẹ Igún gẹ́gẹ́ bí i ikọ̀ ìránṣẹ́ àti àgbébọ:

…ẹbọ ló mórí Igún pá lọ… 5.

àti Ìlà tí ó tọ́ka sí - ìrúbọ sórita … títí dé ìlà kọkànlá (12) ń ṣe àfihàn ìbáṣepọ̀ tí ó ṣe e ṣe kí ó wà láàrin “Ìyà mi” àti Igún bí i ikọ̀ ìránṣẹ́ àwọn ẹlẹyẹ ẹ̀dá.

Gbogbo a-jí-mú-tẹbọ gbó
tIgún ni wọ́n ń ṣe. 10.
Igúnnugún tí í jẹun ẹbọ gbe.
Lábàlúyẹ̀gẹ̀ pé lẹbọ, ó dalákìsà àṣọ. 12
Afínjú ẹyẹ tí í fàkìsà ṣe rọ̀rí…

### 9.11 Ìṣàfihàn Èèwọ̀

Nínú àkíyèsí, oríkì máa ń tọ́ka sí èèwọ̀, ohun ìfẹ́ràn àti àwọn ìdí abájọ tí nnkan fi rí béè nígbà mìíràn. Bákan náà ni ọmọ n sorí bí a bá wo àhùnpọ̀ oríkì àwọn “Ìyà mi” “Àjẹ́” tí a ṣe àtúpalè nínú iṣẹ́ yìí. Bí ó ti jẹ́ pé gbogbo ìṣẹ̀dáà ni ó ní ohun tí ó fẹ́ràn, bákan náà ni ohun tí ó jẹ́ èèwọ̀ má-jẹ́-é, tàbí má-dé-bè wà fún àwọn ìyà mi, tí oríkì fi hàn. Lára ìgbàgbọ́ ìràn ìṣẹ̀dáá ènìyàn nípa èèwọ̀ àwọn “Ìyà mi” ni pé wọ́n kì í jẹ́ èèpò ọ̀bọ̀ tàbí sún mọ́ igi ọ̀bọ̀. Bákan náà ni wọn kì í ṣe ọ̀rẹ́ igi àjẹ́-kò-bà-lé (igi afẹ́lóru).

## 10. Ìkádìí

Kí iṣẹ́ ìwádìí tí a ṣe yìí, tí a sì fẹ́ jẹ́ fún àgbáyé lè ní ìtumọ̀ tó péye, a bu omi ọgbọ́n ọlọ́gbọ́n mu, bẹ́ẹ̀ sì ni a ṣe àfikún ìmọ̀ fún ẹ̀kọ́ àwọn ẹlòmíràn. A ṣe ọ̀rínkínniwín àlàyé lórí àwọn àṣàyan ìṣẹ̀dá ọwọ́ Olódùmarè lójú ìwòye ìrírí, àbùdá ìdámọ̀, ìhùwàsí, ìgbàgbọ́, àti èrò ìjìnlẹ̀ ìran Yorùbá. Bákan náà, a ṣe àgbéyẹ̀wò ìlànà tí ìsọ̀rí àwọn ẹ̀dá abẹ̀mí àti ajẹméranko fi ń ṣe àfihàn agbára tí Aṣẹ̀dà dá mọ́ wọn hàn. A wo ìwọ̀nyìí nípasẹ̀ ìhun oríkì tí àwọn alátinúdá, alárọ̀jinlẹ̀ àwùjọ ń hun mọ́ wọn, nípasẹ̀ ìṣe àti ìhùwàsí wọn. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé, tibi-tire ni a dá ilé ayé, a fi ìjìnlẹ̀ èrò tí ó tẹ̀wọn kín èrò wa lẹ́yìn pé, ohun gbogbo tí Ọlọ́run dá dáradára ni, pẹ̀lú agbára ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀, tí kò fi fún gbogbo ẹ̀dá ní oríkì kan náà. Akíyèsí wa hàn gbangba pé agbára ìṣẹ̀dá wà lọ́wọ́ ẹni tí gbogbo ènìyàn gbà pé ohun ni Olúdá Ayé àti Olúdá ọ̀run. Bákan náà ni iṣẹ́ yìí tanná wo àtúnpín-sísọ̀rí ìṣẹ̀dá mẹ́rin, tí a sì yànnà-ná wọn sí ìsọ̀rí ẹ̀dá ènìyàn, ìsọ̀rí àwọn ìṣẹ̀dá ẹranko tí ó ń bá ènìyàn gbélé, tàbí tí ó ń báni gbé àyíká. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé gbogbo àwọn ìsọ̀rí abánigbé-àyíká mìíràn kì í ṣe ọ̀sìn fún ènìyàn;

síbẹ̀, a wo agbarà ìbágbépọ̀ wọn àti ojúṣe ọ̀kọ̀ọ̀kan àwọn ìsọ̀rí ẹ̀dá náà sí ara wọn, gẹ́gẹ́ bí Aṣẹ̀dá wọn ṣe dá wọn pọ̀. A wo ìsọ̀rí àwọn ẹ̀dá inú omi, àwọn ẹ̀dá tí ó ń jẹ́ nílẹ̀, àti ìsọ̀rí àwọn abìfò-lójú ọ̀run. A fi ojú ìwòye àwọn ìsọ̀rí ẹ̀dá tí ìran Yorùbá gbà pé (apohùn) alátinúdá àti alárọ̀jìnlẹ̀ ni wọ́n; tí wọ́n sì ń hun èrò ìjìnlẹ̀ wọn sínú oríkì fún ìṣàfihàn agbára tí ìṣẹ̀dá ènìyàn, Ìyà mi, àti àwọn ẹranko kọ̀ọ̀kan ní.

Nínú ìtúpalẹ̀ tí a ṣe, ni a ti a wo oríṣìíríṣìí ọ̀nà tí àwọn ọ̀kọrin, akéwì àti apohùn fi máa ń sín àwùjọ ní gbẹ́rẹ́ ìpàkọ́ nípa ìṣẹ̀lẹ̀ àyíká, èèwọ̀ ajẹméranko, àti ọ̀nà ìṣafihàn agbára Olódùmarè nínú ìhun oríkì fún àwọn ìṣẹ̀dá abẹ̀mí àwùjọ. Iṣẹ́ yìí tanná wo àṣàyàn oríkì Ìyà mi (Àjé), àti àwọn ìsọ̀rí ẹ̀yà abẹ̀mí ajẹméranko tí àwọn "Ìyà mi" fí ń ránni níṣẹ́, tí wọ́n fi di ìṣẹ̀dàá olórúkọ alágbára aboniyàn tí Olódùmarè kó ilé ayé lé lọ́wọ́; gẹ́gẹ́ bí oríkì wọn ti fi hàn. Láìsí àníàní, iṣẹ́ yìí yóò fi kún ìmọ̀ lórí àwọn àṣàyàn ìsọ̀rí ìṣẹ̀dá tí a ṣe àtúpalẹ̀ oríkì wọn, àti ìdí abájọ tí àwùjọ fi ń fún àwọn ìsọ̀rí ẹ̀dá kọ̀ọ̀kan ní oríkì tí kò jọra wọn.

**Àkójọpọ̀ Orúkọ Ìwé**


Adeoye, C.L. (1982). *Orúkọ Yorùbá*. Ìbàdàn: University Press Plc.

Adepoju, O. (1989). *Ìrònú Akéwì*. Ibadan: Ọ̀nìbọn-Òjé Press and Book Industries (Nig) Ltd.

Ajayi, O. (2011). *"Agbéyẹ̀wò Oríkì Àwọn Àṣàyan Ẹranko nínú Ìjálá àti Ìrèmọ̀jé"*. Unpublished Masters dissertàtion, Ọbáfẹ́mi Awólọwọ̀ University, Ilé-Ifẹ̀.

Ajíbádé, G.O. (2005). *"Animal in the Traditional Worldview of the Yorùbá"* Folklore 30:3, 155-172.

Ajayi O, àti Ajíbádé, G.O (2021). *Ìtúpalẹ̀ Àṣàyan Oríkì Ẹranko.* Yorùbá Studies Review. Volume 6, Number 1, Spring 2021. 209-233.

Akínyemí, A. (2015). *Yorùbá Royal Poetry: A Socio-historical Exposition and Annotated Translation*. Bayreuth African Studies Series (BASS), 71, 2004).

Akínyemí, A. (1993) Ìlò Oríkì Láwùjo Ilú Òyó. Unpublished PhD thesis of the African languages and Literatures Department. University of Ife.

Àrẹ̀mú, A. (1979). *Àṣàyan Oríkì: Oúnje, Ohun-Ogbin, Eèrà, Ẹyẹ, Ẹranko Àti Ejo.* Ibadan: University Press Ltd.

Aremu, P.S.O, Banjo,B.O; et.al. (2012). "Egungun Tradition in Trado-Modern Society in South-Western Nigeria". *Mediterranean Journal of Social Sciences. Vol. 3 (1) January 2012 ISSN 2039-2117 (*Doi: 10.5901/mjss.2012.03.01.283) *(pp.* 283-289)

Babalọlá, A. (2001). *Àwọn Oríkì Orílẹ̀ Metàdínlógún. Lagos*: National Library of Nigeria Cataloguing in Publicàtion Data.

Biobaku, S.O. (1973). *Sources of Yorùbá History.* Lọndon: Oxford University Press.

Biodun J. Ogundayo. (2009). "Yoruba" in *Encyclopedia of African religions (2nd Edition),*(London: A Sage Reference Publication, 2009)

Daramola, O. Àti Jeje, A. (1975). *Àwọn Àṣà àti Orísa Ilé Yorùbá.* Ibadan: Oníbon-Oje Press.

Frye et al. (1985) *The Harper Handbook to Literature,* New York: fẹ́Harper & Row, Publishers.

Fálẹ́yẹ, A. A. (2011a), "Limiting the Dehumanization of Womanhood: An appraisal Chief (Mrs.) Títí Àtíkù Abubakar's Contributions In *Ìjèsà Icons & The Making of Modern Nigeria*. Oyeweso Siyan. (ed/s.). University Press Plc, Ìbàdàn. Nigeria. (Pp. 221-241).

Fálẹ́yẹ, A. A. (2011b), "Praise Poetry Performance in the Pantheon of Divinities: A Socio-Semantic and Cultural Interpretations" In *Yorùbá*, *Journal of Yorùbá Studies. Association of Nigeria*. Vol. 6, No 1. (pp. 107-138.)

Fálẹ́yẹ, A. A. (2016), "Viewing Oríkì Ọba Okùnadé Àdèlé Síjúwadé Olúbùṣe II

From Socio-cultural and Literary Perspective". *Ifẹ̀ Journal of Languages and Literatures*, Vol. 2, No. 1 (pp. 258-275).
Fálẹ́yẹ, A. A. (2022), *"Gendered Species of Yorùbá Plants: An Ecofeminist Perspective* In Yorùbá Studies Review, Vol 8, No (1): (pp. 67-86). University of Texas.
Ilésanmí, T. M. (2009). *Àwọn Nnkan Abàmì Ilẹ̀ Yorùbá*. Ilé-Ifẹ̀: Ọbáfẹ́mi Awólọ́wọ̀ University Press Ltd.
Ládélé, T.A.A (2006). *Àkójọpọ̀ Ìwádìí Ìjìnlẹ̀ Àṣà Yorùbá.* Ìbàdàn: Gavima Press Ltd.
Ọdúnjo, J.F. (2018). *Aláwìíyé: Iwé Kefa*. Lagos: Learn Africa Plc.
Ògúndèjì, P.A. (1991). *Introduction to Yorùbá Oral Literature*. Ibadan: Centre for External Studies, University of Ìbàdàn.
Olafimihan, J.B. (1953). *Àwọn Ẹ̀dá Alààyè*. London: Longman, Green and Co Ltd.
Odeyemi, J.S. (2013) *Gender Issues Among the Yorubas* in *The International Journal of African Catholicism.* Winter 2013. Volume 4, Number 1.
Isola, S. I. (2023), "Ìtúpalẹ̀ Ìpohùn àti Àmì Inú Àṣàyàn Ìbọ Èwe ní Ilẹ̀ Yewa-Àwórì Ẹ̀gbá àti Among Yewa-Àwórì, Ẹ̀gbá and Ìjẹ̀bú)" Unpublished Ph.D Thesis, Ọbáfẹ́mi Awólọ́wọ̀ University, Ilé-Ifẹ̀.

***Audio CD***
Fálẹ́yẹ, A. A. (2009), *"Ariwo Ayọ̀"* Audio CD Album (An *Ẹ̀sà.Egúngún* and Àdàmọ̀-Ifẹ̀ Performances mode of Presentation). Composed and Produced by Fálẹ́yẹ A. Adéọlá. Vol. 3. Shalom Studios, Ile-Ifẹ̀: Nigeria.
Fálẹ́yẹ, A. A. (2010a), *Ẹ máa tú yagba"* Audio CD Album (An *Ẹ̀sà Egúngún,* and *Àdàmọ̀-Ifẹ̀* Performance modes of Presentation). Composed and produced Fálẹ́yẹ A. Adéọlá in honour of Ọba Okùnadé Ṣíjúwadé Olúbùṣe II, Ọ̀ọ̀ni of Ifẹ̀, on his 8[0th] Anniversary. Vol.4, Shalom Studios, Ilé-Ifẹ̀: Nigeria.
Fálẹ́yẹ, A. A. (2011), "*Jẹ́ ká gbáyé pẹ́…"* An Audio CD Album (featuring *Ẹ̀sà Egúngún,* chanting modes of presentation). Composed and Produced by Fálẹ́yẹ A. Adéọlá. Vol.6. Shalom Studios, Ilé-Ifẹ̀: Nigeria.
Fálẹ́yẹ, A. A. (2016), *"Mo Ń Bọ́ba Rèhà…"* An Audio CD Album (rendered in *Ẹ̀sà Egúngún* chanting mode featuring the Òríkì of the incumbent Ọ̀ọ̀ni Adéyẹyè Enììtàn Ògúnwùsì, Ọ̀jájá II lineage, the entire fifty-one royalties crowned in Ifẹ̀, and other seven panegyrics of Yorùbá lineages. Composed and Produced by Fálẹ́yẹ A. Adéọlá. Vol.7. 101 Audio-visual Studios, Òṣogbo: Nigeria.
Fálẹ́yẹ, A. A. (2018), *"Onínúure lọ"* An Audio CD Album (rendered in *Ẹ̀sà Egúngún* chanting mode, in honour of late Prof Akínwùmí Ìṣọ̀lá and Ìlọ̀kó lineage. Composed and produced by Fáléye Adijat Adéólá. Vol.9. 101 Audio-visual Studios, Òsogbo: Nigeria.
Fálẹ́yẹ, A. A. (2024) *Àkójọpọ̀ Ewì Àtinúdá* – (In Press).

Internet/Online References
*Facebook Source*
Ifátọ́la Akínwùmí (2021), The Power of Ifá. *Oríkì àwọn Ìyà mi* Facebook Page. 21 Dec. 2021. Https:// audiomack.asabioje.afenapa.com

**Audio-visual CD**
Tópé Àlàbí (2005) "*Mo rí Ìyanu*" Produced by Remdel Optimum Communications, Nigeria.
Tópé Àlàbí (2014) "*Orúkọ Tuntun*" Produced by Remdel Optimum Communications, Àkúré, Nigeria.

Sulaimon Ayilara (Ajóbíewé) *Oríkì Orílẹ̀* (1 & 2) – Utube versión (2009).

Recebido em: 23/02/2025
Aceito em: 24/06/2025

**Para citar este texto (ABNT):** ÒGÚNLỌLÁ, Ọmọlayọ̀ Dúrótadé. Ojúṣe èrò ìwòran nínú àgbéjádé lítíréṣọ̀ alohùn yorùbá. *Njinga & Sepé:* Revista Internacional de Culturas, Línguas Africanas e Brasileiras. São Francisco do Conde (BA), vol.5, nº Especial I, p. 80-110, jan./jun.2025.

**Para citar este texto (APA):** Ògúnlọlá, Ọmọlayọ̀ Dúrótadé (jan./jun.2025). Ojúṣe èrò ìwòran nínú àgbéjádé lítíréṣọ̀ alohùn yorùbá. *Njinga & Sepé: Revista Internacional de Culturas, Línguas Africanas e Brasileiras.* São Francisco do Conde (BA), 5 (Especial I): 80-110.